# Àkùngbá Journal

*of*

# LINGUISTICS

*and*

# LITERATURES

No 9. (Special Edition) 2018

ISSN 2141-5420

**©Àkùngbá Journal of Linguistics and Literatures 9 (Special Edition) 2018**
**Department of Linguistics and Languages,**
**Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko,**
**Ondo State, Nigeria.**

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced or transmitted in any form or by any means without permission. Please contact the Managing Editors.

**The Managing Editors**
Bólúwají Oshodì (Ph.D)
bolu_oshodi@yahoo.com

Deborah Arówóṣẹgbẹgbẹ́ (PhD)
dbamidelearowosegbe@gmail.com

**NOTES TO CONTRIBUTORS**

**Àkùngbá Journal of Linguistics and Literatures** is published annually. However, the Editorial Board of the Journal has decided that the Journal will now have two issues per year due to the large numbers of quality papers received annually Its focus is on the publication of recent findings in African Linguistics, Literatures & Cultures. Papers could be written either in quality English or Yorùbá language.

Authors are encouraged to submit their papers online to the Managing editors. The manuscripts should contain original material that has not been published in any form elsewhere. Manuscripts should be double-spaced and on single sides, with ample margins and bear the title of the contribution and the name(s) of the author(s) on a separate sheet of paper. The full postal address/phone/email details of each author including a short biographical note should be provided. The manuscripts should be in 12-point Time New Roman. Contributions should normally be between 10 (ten) and 15 (fifteen) pages. Any paper grossly exceeding this guideline will be subjected to an extra-charge. The manuscripts should include an abstract of not more than 200 words. The journal uses note where necessary. Footnotes are discouraged, only endnotes are allowed. Endnotes are signaled in the text by superscript. Papers should contain

references at the end. The references should include all items referred to in the paper. References are cited in the text thus: author, date, page, an alphabetical reference page should follow the text (and endnotes if any). Contributions that do not conform to the requirements above may be rejected.


**Editor in Chief**
Assoc Prof. Tèmítọ́pẹ́ Olúmúyìwá

**Assistant Editors**
Bolu Oshodi PhD
Deborah Arowosegbe PhD
Simeon Olaogun PhD

**Consulting Editors**

| | |
|---|---|
| Prof. L.C Yuka | University of Benin |
| Prof. Adédọ̀tun Ogúndèjì | University of Ibadan |
| Prof. Fẹ́mi Adéwọlé | Ọbafẹ́mi Awólọ́wọ̀ University |
| Prof. M. A. Abíọ́dún | Èkìtì State University |
| Prof. Dúró Adélékè | University of Ibadan |
| Prof. O. Ajíboyè | University of Lagos |
| Assoc Prof. F.A Fabùnmi | Ọbafẹ́mi Awólọ́wọ̀ University |

# ÀGBÉYẸ̀WÒ ORÍKÌ ẸGBÁ ÀTI ÀWỌN OLÚ-ÌLÚ ABẸ́ RẸ̀

**Olufẹmi Hezekiah ADEỌṢUN**
Department of Linguistics and Nigerian Languages University of Ilorin, Ilorin.
E-mail: hezekiah@unilorin.edu.ng
àti
**Ọmọ́bọ́láńlé Olúwábùsáyọ̀ OYÈKÚNLÉ**
busayooyekunle9@gmail.com

**Àṣamọ̀**

*Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni iṣẹ́ tó wà lórí oríkì, gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ewì alohùn Yorùbá, bẹ́ẹ̀ náà ni a ní oríṣiriṣri àgbàsílẹ̀ lórí oríkì àwọn ẹ̀yà tí à ń pè ní Ẹ̀gbá láàárin àwọn Yorùbá. Yàtọ̀ sí àwọn rẹ́kọ́ọ̀dù láti ọwọ́ Suleiman Ayìlárá (Ajóbíewé), Ọlátúbọ̀sún Ọládàpọ̀, àti àwọn mìíràn, kò tí ì sí àgbàsílẹ̀ oríkì Ẹ̀gbá àti ti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀ ní kíkún, kò sì tí ì sí iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ kankan tó hàn sí aṣèwádìí yìí tó gùn lé tíọ́rì ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ lórí wọn. Àìfi bẹ́ẹ̀ kà àwọn ewì alohùn Yorùbá sí, pàápàá oríkì, ló gún wa ní kẹ́ṣẹ́ inú fún iṣẹ́ yìí. Èròngbà iṣẹ́ yìí ni láti dí àlàfo tó wà lórí àìsí ọ̀pọ̀ iṣẹ́ lórí oríkì Ègbá àti àwọn olú-ìlú abẹ́ rè. Ọgbọ́n ìṣèwádìí tí a mú lò ni ṣíṣe àgbàjọ ìtàn orírun àti oríkì àwọn Ẹ̀gbá ní ìjọba ìbílẹ̀ Gúúsù Abẹ́òkúta, Àríwá Abẹ́òkúta àti Ọbáfẹ́mi Owódé, níbi tí a ti lè rí àwọn olú ìlú Ẹ̀gbá mẹ́rẹ̀ẹ̀rin; Aké, Òkè-ọnà, Àgùrá àti Òwu, a sì yan abẹ́nà-ìmọ̀ márùn-ún tí ọjọ́ orí wọn wà láàárin ọgọ́ta sí ọgọ́rùn-ún ọdún. A ṣàmúlò tíọ́rì ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọfún ìtúpalẹ̀ àwọn oríkì tí a gbà. Ìmọ̀ ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ jẹ́ ẹ̀ka lábẹ́ ìmọ̀-ìlò-àmì tó ń wádìí ìṣe ẹ̀dá tó lápẹẹrẹ nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmáwùjọ àti ajẹmáṣà, tí ó sì ń gbìyànjú láti ṣàlàyé ìfúnnitumọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìṣe àwùjọ. Tíọ́rì yìí pín sí ọ̀nà méjì gbòógì; ọ̀gangan-ipò-ìṣẹ̀lẹ̀ àti ọ̀gangan-ipò-àṣà. Ọ̀gangan-ipò-ìṣẹ̀lẹ̀ ní tirẹ̀ ní ọmọ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ lábẹ́; orí-ọ̀rọ̀-afọ̀, ìṣọwọ́ṣafọ̀ àti ọ̀nà ìgbàṣafọ̀. Ìṣàmúlò tíọ́rì yìí ló fún iṣẹ́ àkànṣe yìí ní àǹfààní láti ṣe àfàyọ àwọn ìṣe ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan, tí a sì tún ṣe ìfúnnitumọ̀ tòótọ́ fún àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwọn oríkì náà. Iṣẹ́ yìí ṣe àkíyèsí pé oríkì Yorùbá jẹ́ ọ̀nà pàtàkì tí ènìyàn lè gbà tọpinpin orírun ẹnikan, ìdílé, tàbí ìlú kan. Ṣùgbọ́n àwọn ènìyàn kò ka oríkì àti àwọn ewì alohùn Yorùbá tó kù sí mọ́, pàápàá àwọn ọmọ bíbí ilẹ̀ Yorùbá gan-an. Àpilẹ̀kọ yìí dábàá kí a túbọ̀ tẹra mọ́ àgbàjọ, ṣíṣe àkọsílẹ̀ àti ìtúpalẹ̀ àwọn ewì alohùn Yorùbá, kí wọ́n má baà lọ sí òkun ìgbàgbé.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Orìkì Ègbá, Ìmọ̀ Ìlo-Ewì Ajẹmáwùjọ, ọ̀gangan Ipò àṣà

## 1. Ìfáàrà

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí àwọn ẹ̀ka lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, pàápàá jùlọ, ẹ̀wì alohùn. A ti rí àwọn ìwé lórí ewì alohùn Yorùbá kọ̀ọ̀kan tí a lè tọ́ka sí ìṣàmúlò oríṣiríṣi ọ̀nà tí àwọn ènìyàn ti gbà ṣe iṣẹ́ lórí wọn. Àwọn onímọ̀ kan ṣe àkójọ tàbí àgbàjọ àwọn ewì alohùn Yorùbá kan sínú ìwé lásán, àwọn kan sì ṣe àkójọ pẹ̀lú ìtúpalẹ̀ àwọn ewì alohùn ní tiwọn. Ọlábímtán (1971) ṣe ìtúpalẹ̀ ọfọ̀ láti fúnni ní ìmọ̀ sí i lórí rẹ̀. Babalọlá (1973) ṣe àkójọpọ̀ orin tí àwọn ọdẹ máa ń kọ níbi ayẹyẹ, tó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ohùn ẹnu Yorùbá. A tilẹ̀ tún rí èyí tí Babalọlá (1975) ṣe lórí oríkì àwọn èèyàn ńlá àti àwọn gbajúmọ̀ ènìyàn láwùjọ, tí àwọn Yorùbá ń pè ní bọ̀rọ̀kìnní ènìyàn.

Abímbọ́lá (1977) ṣe akitiyan láti kó àwọn ẹsẹ-Ifá jọ, ó sì ṣàlàyé àwọn ìtàn tó rọ̀ mọ́ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ẹsẹ-Ifá náà, èyí yóò sì ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ̀gbẹ̀ri tó bá fẹ́ nímọ̀ nípa orísun ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ojú-odù náà. Nínú ìwé Ọlátúnjí (1984) ni a ti rí àkójọpọ̀ àwọn ewì Yorùbá bí oríkì, ẹsẹ-Ifá, ọfọ̀, òwe àti àlọ́ àpamọ̀ níbi tí ó ti tú ìfun àti ẹ̀dọ̀ àwọn ewì alohùn Yorùbá yìí lọ́kọ̀ọ̀kan. A rí àsọdátọ̀ ọ̀rọ̀ lórí àbùdá ẹ̀yà ewì kọ̀ọ̀kan àti àwọn èròjà inú wọn, ìṣàpèjúwe ìhun àwọn ewì náà kò gbẹ́yìn. Àjàyí (2014) ṣe ìtúpalẹ̀

ọfọ̀ ní ìlànà tíọ̀rì ìṣọwọ́-lo-èdè, tí ó sì tú ìfun àti ẹ̀dọ̀ àwọn ọfọ̀ tí ó yàn láàyò nínú iṣẹ́ náà, iṣẹ́ yìí sì jẹ́ ohun èlò pàtàkì fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ìmọ̀ ìṣọwọ́-lo-èdè. Adéyẹmí (2014) fi tíọ́rì sosiọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ṣe ìtúpalẹ̀ oríkì Aláàfin Ọ̀yọ́, tí ó sì jẹ́ ká rí oríkì lọ́nà tó yàtọ̀, nítorí ó ṣàfihàn ìrísí àti ìríri ọba lásìkò wọn. Iṣẹ́ náà tún jẹ́ kí á mọ pàtàkì oríkì orílẹ̀, pé bí orúkọ ṣe ṣe pàtàkì tó fún Yorùbá náà ni orílẹ̀ jẹ́.

Oríṣiríṣi àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí àti àwọn mìíràn ni a ti rí lórí ewì lédè Yorùbá, ní èyí tí a fi ṣe àtẹ̀gùn fún iṣẹ́ yìí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a ti rí iṣẹ́ lórí oríṣiríṣi ewì alohùn àdúgbò ìlú Ẹ̀gbá bí Àrùngbè, orin Orò Ẹ̀gbá tí Ayéláàgbé (2013) ṣe, a kò tí ì rí iṣẹ́ lórí oríkì Ẹ̀gbá àti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀ ní ìlànà tíọ̀rì ìmọ̀-ìlo-àmì-ajẹmáwùjọ, èyí yóò sì jẹ́ kí á mọ ìwúlò àti ìdí àwọn nǹkan tí a ó ba pàdé nínú oríkì ìlú Ẹ̀gbá. Pàtàkì ohun tó jẹ iṣẹ́ yìí lógún jù ni ewì alohùn Yorùbá àti tíọ̀rì ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ, àwọn ọ̀nà tí àwọn apohùn gbà fi oríkì, pàápàá jù lọ oríkì Ẹ̀gbá, sọ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ lọ́jọ̀ nípa ìpàrokò kọyọyọ.

## 2. Ìtàn Ìṣẹ̀dálẹ̀ Ìlú Ẹ̀gbá

Bọ́mọdé bá láṣọ bí àgbà, kò lè lákìísà bí àgbà, bí ọmọdé ò bá sì bá ìtàn, á bá àrọ̀bá, àwọn àgbà sì sọ pé àrọ̀bá ni baba ìtàn. Gbogbo ìlú ní àgbáyé ló bẹ̀rẹ̀ láti ibi kan, kò sí bí ìlú ti lè pẹ́ ní agbègbè kan tó, kó máà ní ibi tó ti ṣẹ̀ wá. Ó tilẹ̀ lè jẹ́ ibi tí ìlú náà wà gan an ni orírun rẹ̀, tàbí kí ó jẹ́ pé ọ̀tọ̀ ni orírun rẹ̀, kí ohun kan tàbí òmíràn sì ṣokùnfà bí wọ́n ṣe dé ibi tí wọ́n wà ní àkókò ti à ń sọ̀rọ̀ wọn. Àwọn Ẹ̀gbá tẹ̀dó sí ibi tí à ń pè ní Ọ̀yọ́ báyìí, tí a mọ̀ sí Àgọ́-Ọjà tẹ́lẹ̀ rí. Bíòbákú (2007) nínú Ayéláàgbé (2013, o. i. 72) sọ pé:

> *The Ẹ̀gbá are Yorùbá-speaking people; who, in the course of the well-known dispersal of Odùduwà descendants from Ile-Ifẹ̀ came to occupy the Ẹ̀gbá Forest roughly situated from present Ọ̀yọ́ (formerly Àgọ́-ọjà) to the North and sweeping Westwards towards the coast of the outskirts of their present capitals. They dwelt in little towns and the towns were grouped into three sections, Ẹ̀gbá Aláké, Ẹ̀gbá Òkè-ọnà and Gbágùrá. The three main groups formed a loose federation with the Aláké as its acknowledged paramount ruler, whilst the Ọṣilẹ̀ and the Àgùrá were rulers of their respective sections... Ẹ̀gbá home soon became a large settlement, swollen by the admission of new refugees, especially the remnants of Òwu who were enroute to Gáún down the Ògùn River, but were invited by Ṣódẹkẹ́ to cross Ògùn River into Abẹ́òkúta from Òkè-àtà. They eventually became the fourth section at Abẹ́òkúta.*
>
> *(Àwọn ènìyàn Ẹ̀gbá jẹ́ lára àwọn ọmọ Odùduwà láti Ilé-Ifẹ̀, tí wọ́n wá tẹ̀dó sí Igbó Ẹ̀gbá tó wà ní ibi tí Ọ̀yọ́ wà lónìí (Àgọ́-ọjà tẹ́lẹ̀) títí dé àríwá lọ dé ìwọ̀-oòrùn ibi tí wọ́n wà báyìí, wọ́n ń gbé ní àwọn ìletò kékèèké, àwọn ìlú náà sì pín sí ọ̀nà mẹ́ta, Ẹ̀gbá Aláké, Ẹ̀gbá Òkè-ọnà àti Gbágùrá. Àwọn ìlú yìí dàbí orílẹ̀-èdè tí Aláké sì jẹ́ aláṣẹ lórí wọn, Ọṣilẹ̀ àti Agùrá náà jẹ́ ọba ní tiwọn... Láìpẹ́, ó di ìlú ńlá, nígbà tí àwọn ìsáǹsá ogun, pàápàá àwọn tó kù nínú ogun Òwu ń sá lọ sí agbègbè Gáún, tí Ṣódẹkẹ́ ní kí wọ́n dara pọ̀ mọ́ wọn láti fo odò Ògùn wọnú Abẹ́òkúta láti Òkè-àtà, pẹ̀lú wọn. Wọ́n padà di apá kẹ́rin Abẹ́òkúta.)*

Àwọn kan ní ìtumọ̀ 'Ẹ̀gbá' ni "Ẹ gbà á lọ́wọ́ wọn". Àwọn ọlọ́ṣà ọ̀nà igbó Ẹ̀gbá ló máa ń kígbe "gba ẹrù wọn lọ́wọ́ wọn" tó di "Ẹ gbà á". Àwọn mìíràn ní ọ̀nà tí àwọn alájàpá ń gbà lọ sí etí òkun, ní igbó Ẹ̀gbá, tí kò sí ọ̀nà kan tààrà "Ẹ gbà á sọ́tùn-ún, Ẹ gbà á sósì, Ẹ gbà á báyìí", ló padà di Ẹ̀gbá. Bíòbákú

(2007) nínú Ayélàágbé (2013) fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé ó ṣe é ṣe kó jẹ́ lílawọ́ tí àwọn ènìyàn yìí lawọ́, tí wọ́n máa ń fi nǹkan fún àwọn arìnrìnàjò, "Ẹ gbà á o!" "Ẹ gbà á o!!", ló fa orúkọ náà.

Ìlú Ẹ̀gbá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìlú tí kò sí ní ibi orírun wọn mọ́ lónìí. Ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ilẹ̀ Yorùbá tí ó ti kojú oríṣiríṣi ogun abẹ́lé, èyí tí ó ṣe é ṣe kí ó ti pa ìlú mìíràn run ti pé, ṣùgbọ́n tí ìlú Ẹ̀gbá borí àwọn ogun náà, tí ó sì gbilẹ̀-gbilẹ́-gboko ní ibi tí wọ́n wà lónìí, tí à ń pè ní Abẹ́òkúta, ìyẹn olú-ìlú ìpínlẹ̀ Ògun, ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí a mọ̀ sí Ẹ̀gbá yìí ní àwọn Ìbàràpá wà ní àríwá wọn, Ìbàdàn àti Ìjẹ̀bú ló wà ní gúúsù wọn, àwọn Àwórì àti Rẹ́mọ ló wà ní ìlà-oòrùn wọn, tí àwọn Ẹ̀gbádò tí a mọ̀ sí Yewa sì wà ní ìwọ̀-oòrùn wọn.

Oríṣiríṣi ni ohun tó kojú àwọn ènìyàn tí à ń pè ní Ẹ̀gbá kí wọ́n tó di ohun tí a lè máa gbé oríkì wọn yẹ̀wò lónìí. Ọkan lára wọn, tí ó tún dà bí èyí tó ṣe pàtàkì jù lọ ni ti ẹni tí wọ́n ń pè ní bàbá Ẹ̀gbá, ìyẹn Líṣàbí Agbòǹgbò Àkàlà. Ajíṣafẹ́ (1972) sọ pé ọmọ bíbí Ìtòkú ni bàbá Líṣàbí ọmọ Ládèjì, tí òún sì tẹ̀dó sí Ìgbèìn tí í ṣe ìlú ìyá rẹ̀. Nígbà tí àwọn ìlàrí tí Aláàfin Ọ̀yọ́ fiṣẹ́ lé lọ́wọ́ láti máa gba ìṣákọ́lẹ̀ àtayébáyé rẹ̀ láàárín àwọn ìlú Ẹ̀gbábẹ̀rẹ̀ sí ní jayé ìjẹkúje, tí èyí kò sì tẹ́ Líṣàbí lọ́rùn ni ó dá ẹgbẹ́ kan sílẹ̀ tí ó pè ní ẹgbẹ́ Ààró. Ẹgbẹ́ yìí ni ó padà di ẹgbẹ́ Olórógun lónìí. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yìí a máa ran ara wọn lọ́wọ́ níbi iṣẹ́ oko, wọn sì máa ń sọ iṣẹ́ ogójì ọjọ́ di èyí tí yóò di ṣíṣe lóòjọ. Àǹfààní ńlá yìí sì mú kí ẹgbẹ́ náà gbòòrò láàárín àkókò díẹ̀ tí ó fi ní ọmọ ẹgbẹ́ tó tó àádọ́ta láàárín àwọn ọmọ Ẹ̀gbá. Líṣàbí ń fara ṣiṣẹ́ ní gbogbo oko tí èyíkéyìí ọmọ ẹgbẹ́ bá ti pè é sí, kò sì bẹ ọmọ ẹgbẹ́ ní ọ̀wẹ̀ kankan ní tirẹ̀.

Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ akitiyan fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ tó kù, Líṣàbí pe ìpàdé pé òún ṣetán láti gba ààró ti òun. Ó jẹ́ kí wọ́n rí ìdí tí àwọn ṣe gbọ́dọ̀ ṣẹ́gun Ọlọ́yọ̀ọ́, ó sì sọ fún wọn pé ọjọ́ tí wọ́n bá gbọ́ pé òún pa ajẹ́lẹ̀ tí Ọlọ́yọ̀ọ́ fi ṣàkóso ìlú Ìgbèìn tí òún wá ni kí oníkálùkù wọn náà pa gbogbo ajẹ́lẹ̀ ìlú ti wọn náà. Láìpẹ́, òkìkí kàn lówùúrọ̀ ọjọ́ kan pé Líṣàbí ti pa ajẹ́lẹ̀ ìlú Ìgbèìn, bẹ́ẹ̀ ni gbogbo ọmọ ẹgbẹ́ ààró ṣe bẹ̀rẹ̀ sí mú àdéhùn wọn ṣẹ, tí wọn sì pa ẹgbẹ̀ta ajẹ́lẹ̀ ní ọjọ́ náà, ẹgbẹ́ yìí sì mú kí gbogbo ọmọ Ẹ̀gbá di ọ̀kan ṣoṣo. Nígbà tí Aláàfin Ọ̀yọ́ gbọ́ èyí, ó ṣígun Ọ̀yọ́, Ìbàràpá, Ẹ̀gbádò, Ìlarò àti Ìjànná sí Líṣàbí. Líṣàbí ti gbúròó èyí, ó sì kó àwọn ará Ìgbèìn lọ sá pamọ́ sínú ọ̀gbun Mélégun, wọ́n sì fi ogun ẹ̀yìn ja àwọn ọmọ ogun Aláàfin Ọ̀yọ́. Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún, ìtàn sọ fún wa pé Líṣàbí wọlẹ̀ láàyè pẹ̀lú àwọn ọmọ rẹ̀ méjè, tafàtafà rẹ̀ márùn-ún àti akọ́dà rẹ̀ méjì.

Ohun mìíràn tí a tún rí gbọ́ ni pé nígbà tí Líṣàbí ti ń dàgbà, àwọn kan wá kóra jọ pé ó ṣe é ṣe kí Líṣàbí fẹ́ jẹ ọba lé àwọn lórí kó sì máa béèrè irú ìṣákọ́lẹ̀ tí Aláàfin Ọ̀yọ́ ti ń béèrè lọ́wọ́ wọn tẹ́lẹ̀ rí, èyí ló wá mú kí wọ́n lọ tàn án lọ sí ibi tí wọ́n pè ní igbó Líṣàbí nísinsìyí, ní èrò wí pé wọ́n fẹ́ dá òun lọ́lá lóòótọ́. Ààrọ̀ kútùkùtù ni wọ́n jí lọ pè é nílé láìmúra tí kò sì ṣe é ṣe fún un láti dira oògùn kankan lásìkò náà. Nínú igbó yìí ni wọ́n ti tì òun àti àwọn ènìyàn rẹ̀ jábọ́ láti òkè, tí wọ́n sì lọ sí inú ìlú láti lọ pa gbogbo ìdílé rẹ̀ run. Ẹ̀gbá figi gún ojú olóore, Líṣàbí sì fi ìran Ẹ̀gbá gégùn-ún nígbà tí ó fẹ́ kú pé àwọn Ẹ̀gbá kò ní lè tọ́ka sí ìlọsíwájú kankan nítorí wọ́n fi ibi san oore tí òún ṣe wọ́n, tí ègún náà sì jà fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún lẹ́yìn ikú rẹ̀.

Ní ọdún 1986 ni Ọba Oyèbádé Lípẹ̀dé, tí í ṣe Aláké kẹsàn án, kọ́kọ́ ṣètò bí àwọn Ẹ̀gbá yóò ṣe máa rántí àwọn akọni wọn tí ó ti lọ, bí i Líṣàbí, Lámọdi, Ṣódẹkẹ́, Lúnlóyè, Tinúbú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, pàápàá Líṣàbí tí ó jẹ́ olóore Ẹ̀gbá àkọ́kọ́. Àwọn Ẹ̀gbá pinnu láti ya ọjọ́ kan sọ́tọ̀ láti máa fi ṣèrántí Líṣàbí àti àwọn akọni tó kù, láti ìgbà tí wọ́n sì ti bẹ̀rẹ̀ sí ní lọ sínú igbó Líṣàbí lọ ṣe ètùtù yìí ni ìlọsíwájú ti ń dé bá àwọn ọmọ Ẹ̀gbá lọ́kọ̀ọ̀kan àti ìlú Ẹ̀gbá lápapọ̀, nítorí ìgbàgbọ́ wọn ni pé Líṣàbí bẹ̀rẹ̀ sí ní yọ́nú sí wọn. Ní ọdún 2006, lẹ́yìn àjọ̀dún kọkànlélógún ni Ọba Adédọ̀tun Àrẹ̀mú Gbádébọ̀ àti àwọn lọ́balọ́ba

yí i padà sí ọ̀sẹ̀ kan, pé ọjọ́ kan kò tó fún gbogbo àwọn akọni Ẹ̀gbá tó ti lọ, tí wọ́n sì ń pè é ní ỌSẸ̀ LÍṢÀBÍ (Líṣàbí Week Celebration), tí ọ̀sẹ̀ náà sì kún fún oníruurú ayẹyẹ àti ètò lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan.

Àpáta Olúfimọ jẹ́ òkúta iyebíye tó ti wà láti ìgbà láéláé ní agbègbè ibi tí Orílé Ìtokò àti Ìjẹmọ wà, tó jẹ́ àárín gbùngbùn ìlú Abẹ́òkúta. Ọdún 1821 sí 1828 ni ogun Òwu bẹ̀rẹ̀ ní ọjà Apòmù, ogun yìí lo ọdún méje, ó sì fọ́ Orílé Òwu. Ní àkókò yìí, àwọn Ẹ̀gbá ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ṣì wà lábẹ́ Ọ̀gágun Máyẹ̀. Ìdòwú Lípẹru ló kọ́kọ́ tẹ̀do sí Abẹ́òkúta, tí Láfá ìgbà náà sì ràn án lọ́wọ́ láti kọ́ ilé àkọ́kọ́ ní ìlú Abẹ́òkúta sí ọ̀kánkán agboolé tó dojúkọ ibi tí ilé Ògbóni Ìtokò wà nísisìnyí. Àwọn ọdẹ mẹ́ta kan, tí orúkọ wọn ń jẹ́ Jíbúlù, Ọ̀ṣọ́ àti Olúnlé, ni wọ́n kọ́kọ́ lọ dara pọ̀ mọ́ Lípẹru níbẹ̀, ṣùgbọ́n wọn kò kọ́ ilé bí i tirẹ̀, dípò bẹ́ẹ̀, wọ́n gbé nínú ihò òkúta ńlá kan níbẹ̀, èyí tí a mọ̀ sí àpáta Olúmọ nísìnyí.

Kí àwọn Ẹ̀gbá tó kúrò ní Orílé wọn ni wọ́n ti máa ń gbọ́ ìròyìn òkúta náà. Wọ́n dá ifá láti mọ bí ibẹ̀ yóò ti tù wọ́n lára sí, ifá ní kí wọ́n rán ikọ̀ lọ bu iyẹ̀pẹ̀ ibẹ̀ wá. Àwọn ọdẹ mẹ́ta yìí ni wọ́n fún Abẹ́òkúta ní orúkọ nípa ṣíṣe àpèjúwe ibi tí wọ́n ń gbé fún ikọ̀ tí àwọn Ẹ̀gbá rán wá. Abẹ́òkúta yìí ni a tún mọ̀ sí Oko-Adágbá, nítorí arákùnrin alágbára kan tí òun náà tún tẹ̀dó sí ibi kan léti àpáta Olúmọ náà, tí òun nìkan sì ṣẹ́gun àwọn ẹgbẹ́ onísùnmọ̀mí Ọ̀yọ́ lẹ́ẹ̀mejì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, tí ó mú kí orúkọ rẹ̀ gbilẹ̀ dáadáa, tí ó sì di orúkọ kejì tí a fi ń pe Abẹ́òkúta. Ifá tí wọn fi iyẹ̀pẹ̀ ibẹ̀ dá fọ ire, ó ní ibi tí wọ́n fẹ́ lọ dó sí náà yóò tù wọ́n lára. Ajíṣafẹ́ (1972, o.i. 53) àti amọ̀nà ọba nígbà kan ní ilẹ̀ Ẹ̀gbá, olóògbé Olóye B.P. Ṣórúnkẹ́ sọ nínú Ayéláágbé (2015) pé Ogbè Òfunsà ni wọ́n rí lójú Ọpọ́n.

Ní sáà Lámọdi ará Ìgbèin nípò Balógun Ẹ̀gbá àti Ṣódẹ́kẹ́ ará Ìpóró nípò Séríkí Ẹ̀gbá ni àwọn Ẹ̀gbá wò ó pé àwọn ṣetán láti kúrò lábẹ́ àkóso Ọ̀gágun Máyẹ̀. Wọ́n fi tó Máyẹ̀ léti pé àwọn fẹ́ lọ ṣètùtù kan lókè Odò-Ọnà, ṣùgbọ́n Máyẹ̀ kò gbà wọ́n gbọ́, ó ní àfi bí wọ́n bá da obì kó yàn. Lósì, ọ̀kan lára Ògbóni Ẹ̀gbá da obì ṣùgbọ́n kò yàn, ó sì dá ọgbọ́n sí i. Lẹ́yìn-ò-rẹyìn, Máyẹ̀ mọ̀ pé irọ́ ni àwọn Ẹ̀gbá ń pa fún òun, ó sì ṣígun sí wọn. Ogun yìí ni Lámọdi bá lọ, lẹ́yìn tí Ẹ̀gẹ̀ tí í ṣe ọ̀rẹ́ rẹ̀ dà á, níbi tó ti ń gbìyànjú láti gba ọmọ rẹ̀ Ọ̀ṣọtà lọ́wọ́ ogun Máyẹ̀.

Oṣù kéjọ ọdún 1830 ni Ṣódẹkẹ́ ìlú Ìpóró kó àwọn Ẹ̀gbá dé ibi tí wọ́n wà lónìí yìí, èyí ló sì fa ìdásílẹ̀ Abẹ́òkúta. Abẹ́ Olúmọ ni wọ́n kọ́kọ́ dé sí, tí wọ́n fi ṣe àábò. Láti abẹ́ Olúmọ ni àwọn ènìyàn Ẹ̀gbá ti bẹ̀rẹ̀ sí ní lọ tẹ̀dó sí àwọn ìletò kọ̀ọ̀kan, tí wọ́n fi wá ń di ìlú lóríṣiríṣi, tí ètò ìṣèlú, ètò-ọrọ̀-ajé, àṣà àti ẹ̀sìn wọn fi bẹ̀rẹ̀ sí fẹsẹ̀ rinlẹ̀ dáadáa níbẹ̀ tó fi di ìlú nlá tó wà lónìí. Lákòókò yìí, ọba Láfá kìíní, tí ó jẹ́ baba ńlá Olúbarà tó wà lórí oyè báyìí, ni ó wà lórí oyè, tí Orílé Ìbarà kò sì jìnnà sí aginjù igbó tí àwọn Ẹ̀gbá wá tẹ̀dó sí. Èyí ló fa kí wọ́n máa ki Ìbarà ní 'Aláyà GbẸ̀gbá Dó'. Ẹ̀gbá etídò ni wọ́n máa ń pé Ìbarà ri, ṣùgbọ́n ní báyìí, wọ́n ti yí orúkọ padà di Yewa. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ìbarà kì í ṣe ara Ẹ̀gbá, a kò lè sọ̀rọ̀ Ẹ̀gbá láìmẹ́nu bà Ìbarà nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ oore tí àwọn Ìbarà yìí ṣe fún àwọn Ẹ̀gbá. Lára rẹ̀ ni kíkọ́ tí wọn kọ́ wọn bí a ṣe ń tan iná àti bí a ṣe ń rí ẹja jẹ, Ìbarà fi ọmọ ọba wọn rúbọ sí ojúde tí wọ́n ti ń ṣe gẹ̀lẹ̀dẹ́ lónìí kí àwọn obìnrin Ẹ̀gbá lè rọ́mọ bí, àti àwọn oore mìíràn.

Ọdún 1834, tí í ṣe ọdún kẹ́rin lẹ́yìn tí àwọn Ẹ̀gbá mẹ́ta, Aké, Òkè-Ọnà àti Àgùrá, dé Abẹ́òkúta, ni àwọn tó kù nínú ogun Òwu wá dara pọ̀ mọ́ wọn. Ṣódẹ́kẹ́, tí òun àti Lámọdi jọ jìjà gba àwọn ọmọ Ẹ̀gbá lábẹ́ àkóso Ọ̀gágun Máyẹ̀, tí ó sì kó wọn dé ibi tí wọ́n wà lónìí, nígbà tí Lámọdi bógun lọ ní tirẹ̀, ni ó ké sí àwọn isáǹsá ogun Òwu pé kí wọ́n máa wulẹ̀ ré kọjá òkè-odò lábẹ́ àkóso Ọmọọba Láàrà àti olóyè Olúfakun Balógun ìlú Òwu nígbà náà. Bayìí ni àwọn ìlú tó para pọ̀ di Ẹ̀gbá ṣe kóra jọ pọ̀ síbẹ̀, tí díẹ̀ lára àwọn ènìyàn wọn tó kù ní àwọn ìletò tí wọ́n ti wá náà sì wá láti wá dara pọ̀ mọ́ wọn tí wọ́n sì ń gbé pọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìlú àti ọmọ ìyá. Nígbà tó di ọdun 1893 ni àwọn ọba mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ṣèpàdé láti sọ Ẹ̀gbá di

ọkan, tí wọ́n sì fi lélẹ̀ ní ọjọ́ kìíní, oṣù kejì ọdún 1898. Ayé kò fi bẹ́ẹ̀ rọrùn nígbà náà, nítorí oríṣiríṣi ni ìdààmú tí ó kojú wọn, yálà gẹ́gẹ́ bí orílẹ̀-èdè Ẹ̀gbá lápapọ̀ ni, tàbí bí ìlú kọ̀ọ̀kan.

**3. Oríkì gẹ́gẹ́ bí Ọ̀kan lára Ewì Alohùn Yorùbá**

Oríkì jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ewì alohùn Yorùbá, ó sì kún fún àwọn oríṣiríṣi ọ̀rọ̀ tí a máa ń fi yin ènìyàn tàbí ki ẹni ti inú wa bá dùn sí. Oríkì ṣe pàtàkì láàárín àwọn ewì alohùn Yorùbá, nítorí ó jẹ́ èròjà tí a kò lè má bàá pàdé nínú àwọn ewì alohùn Yorùbá mìíràn bí ìjálá, rárà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọlátúnjí (1984) sọ nípa rẹ̀ pé:

> *Oríkì is the most popular of Yorùbá oral poetic genres, a fact which is attested to by several collections of the genre. It features in the performance of all Yorùbá chanters as they address members of their audience... (p. 67)*
> *(Oríkì ṣe pàtàkì láàárín àwọn ewì alohùn Yorùbá, gẹ́gẹ́ bí ó ti sú yọ nígbà tí tí a ṣe àkójọpọ̀ ewì alohùn. Ó máa ń jẹ yọ nínú èrò gbogbo àwọn asùnsàré nígbà tí wọ́n bá ń dá àwọn òǹwòran wọn lára ya ...)*

A kò lè sọ̀rọ̀ oríkì láìménu ba orúkọ, nítorí ohun ló dà bí ìpìlẹ̀ fún un. Orúkọ̀ ni a fi ń dá ènìyàn kan tàbí ìdílé kan mọ̀ yàtọ̀ sí òmíràn, ó sì máa ń nípa nínú ìgbésí ayé ẹni tó ni í. Orúkọ máa ń sábà sọ ìrú ìwà tí ọmọ lè hù láyé rẹ̀, oríṣiríṣi sì ni orúkọ láwùjọ Yorùbá, bí a ti ní orúkọ àmútọrunwá, ni a ní orúkọ àbísọ, orúko ìnagijẹ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lẹ́yìn tí ó ti ṣe atótónu díẹ̀ nípa orúkọ, Ọlátúnjí (1984, o.i. 68) wá sọ pé orúkọ ọmọ ní í ro ọmọ gẹ́gẹ́ bí Yorùbá ṣe sọ. Èyí ló fà á tí a kì í fi í kù gbùùrù sọ ọmọ lórúkọ, nítorí àwọn nǹkan tó rọ̀gbà yí ìbí ọmọ náà ká àti ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ẹbí rẹ̀, ìbẹ̀rù àti ìrètí ẹbí náà, gbogbo rẹ̀ ni orúkọ náà gbọ́dọ̀ gbé jáde.

Bí orúkọ ti ṣe pàtàkì náà ni oríkì ṣe pàtàkì láwùjọ Yorùbá, tí ó sì máa ń kó ipa gidi láyé ènìyàn tàbí ohunkóhun tó bá ni í. Oríkì jẹ́ ọ̀nà ìṣura àti ìsọlọ́jọ̀ tí a máa ń lò láti sọ ìtàn ìran tàbí ìdílé kan fún àwọn ọmọ tí a bí nínú irú ìdílé bẹ́ẹ̀, tí yóò sì jẹ́ kí á mọ àwọn nǹkan ribiribi tí ó tí ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn. Akporobaro (2001) nínú Bisiriyu (2014, o.i. 163) sọ pé:

> *Praise poetry is specifically for eulogistic portrayal of virtues of a given subject. The subject of the praise could be a king, leader, an animal or plant. The most characteristic feature of a praise poem is the invocation of the noble and heroic qualities of the subject through the use of approximately suggestive metaphors, symbols and allusion.*
> *(oríkì wà fún gbígbé àwọn àwòmọ́ ẹni tàbí ohun tí à ń kì jáde lọ́nà ìgbóríyìn-fún. Ó lè jẹ́ ọba, aṣáájú, ẹranko tàbí igi ni à ń kì. Àbùdá tó ṣe pàtàkì jù nínú oríkì ni lílo àwọn ẹwà-èdè láti pe àwọn àbùdá akọni tí ẹni tàbí ohun tí à ń kì ní.)*

Oríṣiríṣi oríkì ló wà láwùjọ Yorùbá, bí a ti ní oríkì kúkúrú ni a ní oríkì orílẹ̀, oríkì bọ̀rọ̀kìnì, oríkì ẹranko, oríkì ẹyẹ, oríkì igi àti ewéko. Bí ènìyàn bá ń ṣiṣẹ́ tàbí tí ó ń jó lójú agbo, bí ó bá gbọ́ oríkì rẹ̀, ara rẹ̀ á yá gágá, á sì múra sí ohun tó ń ṣe náà dáadáa. Gbogbo ènìyàn, yálà olówó ni tàbí mẹ̀kúnnù, ló ní oríkì tirẹ̀ tí a lè fi pè é. Kò sí ẹni tàbí ohun tí a kò lè kì, a sì máa ń ki ènìyàn mọ́ oríṣiríṣi nǹkan, bí a ti ń ki ọba tí à ń ki ìjòyè, náà ni a lè ki ẹnikẹ́ni ní ìlú pẹ̀lú, bẹ́ẹ̀ náà ni a lè ki ìlú kan tàbí òmíràn, àwọn apohùn sì máa ń ṣe akitiyan láti mọ oríṣiríṣi oríkì àwọn ènìyàn tó ṣe pàtàkì ní àwùjọ. Ògúnfọlákàn (2002) sọ pé oríkì, tí ó jẹ́ oríṣi ewì Yorùbá kan, jẹ́ ẹ̀ya lítíréṣọ̀ tí ó ṣàkóónú àwọn nǹkan tó ti ṣẹlẹ̀ ṣáájú àsìkò ẹni, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá fúnraarẹ̀, iṣẹ́ tí ẹni náà ń ṣe àti ipa rẹ̀ ní àwùjọ, àwọn ohun tí ẹbí rẹ̀ ti gbé ṣe àti ipò ìlú ẹni náà.

Àkóónú oríkì lóòrìn púpọ̀, ó sì máa ń ju ẹyọ ìlà díẹ̀ lọ, nípa oríkì ẹnìkan tàbí ohun kan, a lè ṣàpèjúwe bí ayé rẹ̀ ti rí láti ìbẹ̀rẹ̀ títí wá dé àkókò tí a gbọ́ oríkì náà. Ó tilẹ̀ lè sọ nǹkan tí ènìyàn yóò gbélé ayé ṣe gan an, nítorí ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ìgbéayé àwọn babańlá ènìyàn máa ń sábàá lapa nínú ayé rẹ̀. A lè fi oríkì ṣàpèjúwe ìrísí ẹnìkan, àwọn àbùdá tí yóò buyì kún irú ẹni bẹ́ẹ̀, bí ìwà akọni tí ó ti hù rí, èyí tí ó bá ní í ṣe pẹ̀lú ìdílé ọba tàbí ìjòyè, agbára oògùn tàbí ìmọ̀ọ̀nṣe rẹ̀ nínú iṣẹ́ tí ó yàn láàyò. Bí ewì alohùn Yorùbá lápapọ̀ ti ní àwọn àbùdá tí a fi ń dá a mọ̀ yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀ka lítíréṣọ̀ alohùn tó kù náà ni oríkì ní àwọn àbùdá tirẹ̀ tó yà á sọ́tọ̀ sí àwọn ewì alohùn Yorùbá tó kù. Ọlátúnjí (1984, o.i. 87) ṣàlàyé pé àwọn àbùdá àdáni oríkì ni ìsọdorúkọ, ìṣàmúlò ọ̀pọ̀ ìpèdè tó ní í ṣe pẹ̀lú ẹbí kan, ìtọ́kasí ẹni tí à ń kì lọ́pọ̀ ìgbà, ìfọgbọgbọ́n-tọ́kasí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbàanì àti àìlétò àkóónú àti ìhun. Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìsọdorúkọ, ó jẹ́ ọ̀nà kan lára àwọn ọ̀nà tí à ń gbà ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ orúkọ nínú èdè kan. Èyí tó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí ni bí a ti ń sọ gbólóhùn di orúkọ, nítorí èyí ni irú ìsọdorúkọ tó máa ń wáyé nínú oríkì Yorùbá. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni ìsọdorúkọ máa ń jẹ yọ nínú oríkì, ó máa ń kó ju ìdajì oríkì kan lọ nígbà mìíràn. A lè sọ gbólóhùn di orúkọ nípa síso àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ mọ́ awẹ́ gbólóhùn, tàbí kí a so àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ mọ́ ọ̀rọ̀ orúkọ.

Àbùdá oríkì Yorùbá mìíràn ni ìṣàmúlò àwọn ìpèdè tó fi ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín ẹbí kan hàn. Àwọn ọ̀rọ̀ yìí ló máa ń so ẹni tí à ń kì pọ̀ mọ́ àwọn babańlá rẹ̀, àti àwọn ìbátan rẹ̀, yálà àwọn tó ti kú ni tàbí àwọn tó ṣì wà. Èyí tó máa ń sábà jẹ yọ ni *ọmọ*. Àpẹẹrẹ látinú oríkì orílẹ̀ Ọ̀bà nílùú Abẹ́òkúta ni:

*Ọmọ yúnwẹ́n*
*Ọmọ yùnwẹ́n-ẹ̀n*
*Ọmọ ṣẹfun tẹ́fun ṣe*
*Ọmọ lẹ̀kọ́lẹ̀ lèrò ọbà*

Ẹni tó ń ki oríkì lè lo orúkọ ẹni tí ó ń kì bí mélòó kan, tí yóò sì máa fi ṣe àpèjúwe irú ẹni bẹ́ẹ̀, ó lè jẹ́ orúkọ àbísọ bí mẹ́rin, ó sì tún lè ṣe àfikún àwọn ìnagijẹ, àlàjẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Akéwì lè ṣàmúlò àwọn orúkọ yìí lásán, ó sì tún lè ṣe ìfibọ̀ wọn.

A tún máa ń mú àwọn ìtàn ìgbàanì wá sí ìrántí, èyí máa ń wáyé láti ṣe àfàyọ àwọn nǹkan akọni tí ẹni tí ìtàn ìgbàanì náà ń tọ́ka sí ṣe nígbà ayé rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1984) ṣe sọ, àwọn bí Obumselu (1966, o.i. 48) gbà pé ìtọ́kasí yìí máa ń mú kí oríkì mìíràn kùnà láti báyé mu, èyí kò rí bẹ́ẹ̀, ìgbà tó wà láàárín àsìkò àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ló fa kó dà bí ẹni pé wọn kò ṣẹlẹ̀ rí. Ọlátúnjí (1984) wá fi ẹnu rẹ̀ jóná pé bí ènìyàn bá fẹ́ ṣe àgbéyẹ̀wò lítíréṣọ̀ àwùjọ kan, kò tọ́ kí irú ẹni bẹ́ẹ̀ máa fi ojú àṣà ilẹ̀ òkèèrè wo irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀, bí kò ṣe pé kí ó mọ àṣà àwùjọ tó bí lítíréṣọ̀ náà fúnraarẹ̀. Àpẹẹrẹ nínú oríkì Ọ̀bà ni ìtàn nípa ọkùnrin kan, Ọ̀ṣọ́ ará Ọ̀bà tó fẹ́ ìyá àti ọmọ papọ̀:

*Ọ̀ṣọ́ ará ọ̀bà fẹ́mọ fẹ́yàá o jàre*
*Haa! Ọ̀ṣọ́ ará ọ̀bà yí fẹmọ fẹ́yàá*
*Ó dẹ̀ fagada yọ*
*Ó wá lé ọkọ junù sí gbàdàyà*
*Ìyí fẹ́mọ fẹ́yàá, kó rojọ́ ẹnu rẹ̀ kó jàre*

Ọ̀pọ̀ àwọn oríkì tó máa ń tọ́ka sí àwọn nǹkan tí ènìyàn kan ti gbélé ayé ṣe ló máa ń jẹ́ pé àwọn àkóónú wọn kì í fi bẹ́ẹ̀ bá ìwà ọmọlúàbí mu, kì í ṣe pé èsóró ti pàdí dà, ṣùgbọ́n òfin tó de èdè oríkì fi ààyè gba kí a máa fi irú àwọn nǹkan bẹ́ẹ̀ yangàn nípa ẹni tí à ń kì bí a ti rí i nínú oríkì Ọ̀bà, ìwà ọmọlúàbí ṣì wà nípò tó wà láàárín àwọn ọmọ ilẹ̀ káàárọ̀-oò-jíire síbẹ̀. Kò sí àwùjọ ẹ̀yà Yorùbá kankan tí a kò ti lè bá oríkì pàdé nítorí ogún ìbí pàtàkì ni ó jẹ́ láàárín wọn.

## 4. Tíọ̀rì ìmọ̀-ìlò-àmì-Ajẹmáwùjọ

Kò sí irú afọ̀ tí kò lè ṣàmúlò tíọ̀rì tí a yàn fún iṣẹ́ àkànṣe yìí, yála alohùn ni tàbí alákọsílẹ̀, èyí ló fà á tí a ó fi ṣàmúlò rẹ̀ fún oríkì Ẹ̀gbá àti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀, tó jẹ́ ewì alohùn Yorùbá, nínú iṣẹ́ àkànṣe yìí. Oríkì, bí àwọn ewì tó kù, náà ní ìṣẹ̀lẹ̀, akópa àti sàkání ìtumọ̀, èyí ló sì mú kí tíọ̀rì yìí ṣe é mú lò nínú iṣẹ́ àkanṣe yìí. Ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ jẹ́ ẹ̀ka lábẹ́ ìmọ̀-ìlò-àmì, èyí tó ń wádìí ìṣe ẹ̀dá tó lápẹẹrẹ nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmáwùjọ àti ajẹmáṣà kan, àti tí ó tún ń gbìyànjú láti ṣàlàyé ìfúnnítumọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìṣe àwùjọ.

Ìmọ̀-ìlò-àmì-àjẹmáwùjọ ni ẹ̀kọ́ nípa ìtumọ̀ ajẹmáwùjọ, àti ọ̀nà tí ènìyàn kan lè gbà so ìtumọ̀ mọ́ nǹkan (ìyẹn ìlò àmì) nípa àwòrán oríṣiríṣi ní ìbámu pẹ̀lú àwùjọ. "Social semiotics focuses on social meaning-making practices of all types, whether visual, verbal or aural in nature." (Thibault, 1991). Èyí túmọ̀ sí pé ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ gbájú mọ́ oríṣiríṣi ìfúnnítumọ̀ ajẹmáwùjọ yálà aláfojúrí, aláfẹnusọ tàbí aláfetígbọ́. Ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ, gẹ́gẹ́ bí Hodge àti Kress (1988) ṣe ṣàkọsílẹ̀ rẹ̀ pé "...can include the study of how people design and interpret meanings, the study of texts and how semiotic systems are shaped by social interests and ideologies, and how they are adapted as society changes" (...ó lè ṣàkóónú ẹ̀kọ́ nípa bí àwọn ènìyàn ṣe ń yàwòrán tàbí ṣàpèjúwe àti bí a ṣe ṣẹ̀dá ètò ìlò àmì látara èrò báyéṣerí àti àǹfààní àwùjọ, àti bí a ṣe gba wọ́n bí àyípadà tó dé bá àwùjọ).

Tí a bá wò ó láti ìhà ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ, àmì ni a kíyèsí bí ọ̀nà ìrọrùn tí àwọn ènìyàn ń lò tí wọ́n sì yàn (tàbí "ṣẹ̀dá") láti dúró fún nǹkankan. Fún ìdí èyí, ìmọ̀-ìmédèlò àti ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè-ajẹmáwùjọ kó ipa pàtàkì lórí ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ, àti pé ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ ń ṣe alábàápín àwọn iṣẹ́ mìíràn tí ìmọ̀-ìmédèlò àti ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè-ajẹmáwùjọ ń ṣe, ó tún ní nǹkan púpọ̀ láti ṣe pẹ̀lú ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ nípa àṣà àti ìtúpalẹ̀ afọ̀ ní ìlànà láméyítọ̀.

Harris (2006) nínú Adéọ̀ṣun (2012, o.i. 107) dábàá pé kí á gbà pé ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ jẹ́ èyí tó ń tẹnu mọ́ pàtàkì ọ̀gangan ìpò, bí àpẹẹrẹ ọ̀gangan-ìpò-ìṣẹ̀lẹ̀ àti ọ̀gangan-ìpò-àṣà, nínú ṣíṣe ìpèsè àpèjúwe ìtumọ̀ afọ̀ kan ní kíkún. Ìfojú-ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ-wò rí èdè bí àpapọ̀ ìgbésẹ̀ ajẹmáwùjọ nínú àwùjọ kan. Àbájáde èrò yìí fi hàn pé ọ̀gangan ìpò ṣe pàtàkì gan an nínú níní òye àti ìfúnnítumọ̀ afọ̀ kan. Gbogbo afọ̀ tí a fi èdè kọ ló ní àsomọ́ pẹ̀lú ọ̀gangan ìpò, kò sí afọ̀ tó lè dá dúró láyè ara rẹ̀. Nítorí náà, kí afọ̀ kan tó lè yéni, a gbọ́dọ̀ pèsè àpèjúwe ní kíkún nípa ọ̀gangan ìpò afọ̀ náà.

## 5. Àgbéyèwò Oríkì Ìlú Ẹ̀gbá àti Àwọn Olú- Ìlú Abé Rẹ pèlú Ìlò Tíórì Ìmò Ìlò- Àmì Ajẹmáwùjọ

Ní abala yìí, ni a ti ṣe àfàyọ àwọn kókó tó wà nínú ọkọ̀ọ̀kan àwọn oríkì àwọn olú ìlú tó para pọ̀ di Ẹ̀gbá; ìyẹn Ẹ̀gbá Aké, Ẹ̀gbá Òkè-Ọnà, Ẹ̀gbá Àgùrá, Ẹ̀gbá Òwu àti Ìbarà aláyà gbẸ̀gbá dó, nítorí a ò lè sọrọ̀ orílẹ̀-èdè Ẹ̀gbá kí á gbàgbé Ìbarà.

Ògúnṣínà (1987, o.i. 19) sọ pé lítíréṣọ̀ ní í ṣe pẹ̀lú ènìyàn àti àwùjọ rẹ̀, lítíréṣọ̀ ni ọkọ̀ tí ó ń gbé èrò ẹ̀dá jáde. Lítíréṣọ̀ máa ń wádìí ènìyàn, ìṣesí àti ìmọ̀ rẹ̀ nípa ara rẹ̀ àti irú àwùjọ tó bá ara rẹ̀. Ìṣàmúlò tíọ̀rì tí a yàn yìí yóò fún wa ní àǹfààní láti sọ ojú abẹ níkòó gan an, kì í ṣe pé a óò máa wá àwọn ìtumọ̀ tí ó ṣe é ṣe kí ó jọ èrò ọkàn oníṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ kan, ṣùgbọ́n a ó lè ṣàlàyé iṣẹ́ tí àwọn akópa ń ṣe, iṣẹ́ tí wọ́n fi èdè jẹ́ àti àwọn ìmọ̀ inú àwùjọ, tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tó ti kọjá tí wọ́n mú wá sí ìṣe.

*Ọgangan-ìpò-ìṣẹ̀lẹ̀*
Níbí ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá àdání àwọn akópa inú àwọn oríkì Ẹ̀gbá àti ti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀, ìbáṣepọ̀ tó wà laàárín àwọn akópa yìí, àti àwọn iṣẹ́ tí wọ́n fi àmúlò irú àwọn èdè tí wọ́n yàn láàyò jẹ́ nínú sàkání ìtumọ̀ kan tàbí òmíràn.

Orí-ọ̀rọ̀-afọ̀: Nínú oríkì tó jẹ́ ti gbogbo ọmọ Ẹ̀gbá lápapọ̀, orí-ọ̀rọ̀-afọ̀ tí a rí tó jẹ yọ jù ni jíjẹ́ akin ní ojú ìjà nígbà tí gbàgede tó jẹ́ sàkání ìtumọ̀ tí orí-ọ̀rọ̀-afọ̀ náà ti ń ṣiṣẹ́ jẹ́ àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́, níbi tí iṣẹ́ ogun ti jẹ́ ohun àjogúnbá wọn, tí ó sì jẹ́ ohun àmúyangàn fún àwọn èyà Yorùbá lápapọ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, èyí ni ó sì wọ́pọ̀ nínú gbogbo àwọn oríkì tí a gbé yẹ̀ wò. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àwòrán tí àwọn oríkì tí a gbé yẹ̀wò ní abala yìí fi èdè yà ló jẹ́ ti ogun, àwọn akópa inú àwọn oríkì yìí jẹ́ jagunjagun, tí gbàgede àti sàkání ìtumọ̀ rẹ̀ sì jẹ́ ìlú Ẹ̀gbá láti ibi tí wọ́n ti wà láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé ibi tí wọ́n wà lónìí. Àwọn akópa nínú oríkì Aké ni a ó ò kọ́kọ́ mẹ́nu bà, ogun jẹ́ ohun tí wọ́n ń fi ojoojúmọ́ ṣe bí iṣẹ́. A fẹ́rẹ̀ lè sọ pé bí ó bá ti pẹ́ tí wọn ò rí ogun jà, wọn gbọ́dọ̀ máa fura bóyá ọ̀tá kan ń gbìyànjú láti gba ọ̀nà tí wọn ò rò wọlé sí wọn lára, ó ní 'Ọmọ ajagun-múṣẹ́-ojo…'

Nínú oríkì Òwu bákan náà, a rí i pé ogun jẹ́ ohun tó ti di bárakú fún wọn, nítorí ojoojúmọ́ ni wọ́n ń jagun. Wọn tilẹ̀ tún ń sọ pé àwọn máa ń jí fi idà ṣeré bí ohun ìṣeré ọmodé, nígbà tí wọ́n ṣàmúlò ẹ̀ka-èdè àdúgbò wọn, ó ní 'Ọmọ a-jí-fepé-ṣeré…'. Bóyá nítorí ogun jẹ́ ohun tí wọ́n ń fi ojoojúmọ́ jà ni, àwọn akópa tí ó jẹ́ ọmọ Ẹ̀gbá mọ̀ bí a ti ń lo orísirísi ọgbọ́n tí yóò tètè jẹ́ kí ènìyàn borí ọ̀tá, nítorí pé wọn ò kì í kọjá àyè wọn. Èyí ni wọ́n fi máa ń pòwe ní agbègbè Ẹ̀gbá pé "ilẹ̀ Ẹ̀gbá kì í yọ ènìyàn lásìkò òjò", ìyẹn ẹni tó bá mọ̀ ọ́n rìn ni. Àpẹẹrẹ èyí ni a rí nínú oríkì Ẹ̀gbá àti ti Àgùrá, tí í ṣe ọ̀kan lára àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀ nísàlẹ̀ yìí:

> *Ẹ̀gbá ọmọ Ládèjì Agbòngbò Àkàlà*
> *A-ṣojo-ṣíwájú-akin*
> *Ẹ̀gbá a ṣàálọ̀ kó tó dìjà wàrà-wàrà…*
> *Àbàtàbútú àlejò tí í ṣonílé dárudáru*
> *Àgbà ńlá òjò tíí lékú wọlé kẹ̀rikẹ̀ri lójú ogun…*

Èyí ń jẹ́ kó yé wa pé àwọn akópa inú àwọn oríkì yìí máa ń fi ara balẹ̀ kílọ̀ ìjà kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ ni, kì í ṣe pé wọn ò kún ojú òṣùwọn, bí kò ṣe pé wọ́n mọ ohun tí àwọ́n lè dí bí ìjà bá bẹ̀rẹ̀ tán. Bí wọ́n bá sì ti bẹ̀rẹ̀ tán, kò sẹ́ni tó lè dá wọn lẹ́kun, nítorí wọn kì í bẹ̀rù lójú ìjà, Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "a kì í dénú omi tán ká máa kígbe òtútù". Bí Àgùrá bá dé ojú ogun, wọn kì í bẹ̀rù àwọn ọ̀tá wọn rárá, èyí ni a rí nínú oríkì wọn tó sọ pé:

> *Ọmọ Gbágùrá*
> *Ọmọ a-rí-wọn-má-ṣojo-lójú-ogun*
> *A-wọ-bàǹtẹ́-ogun-má-fòyà…*
> *Àgùrá ilé Ìdó*
> *Ọmọ alájá bẹ́kùnbẹ́kùn ni baba wọn lójú ogun…*
> *Ọmọ a-wọ-bańtẹ́-ìjà-má-fòyà…*

Iṣẹ́ ogun àfojoojúmọ́ ṣe yìí fún wọn ní àǹfààní láti ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ oògùn tó ní orísirísi iṣẹ́ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ń ṣe. Nígbà tí nǹkan bá ti di bárakú fún ènìyàn tàbí ẹ̀yà kan, a kò lè ṣàìmá rí irú nǹkan báyìí nínú irú àwùjọ bẹ́ẹ̀, nítorí "ojúbọ̀rọ̀ ò ṣe é gbọmọ lọ́wọ́ ẹ̀kùrọ̀", kò sẹ́ni tó fẹ́ kí wọ́n borí òun lójú ogun. Èyí lapa nínú àwọn oríkì náà pé àwọn ọmọ Ẹ̀gbá tó wà ní ìtòsí àti àwọn tó wà lọ́nà jínjìn ni wọn ní oògùn yìí

dáadáa, nítorí ohun àmúṣagbára wọn ni, títí di àsìkò tí à ń sọ̀rọ̀ yìí, òpò nínú àwọn Ẹ̀gbá ṣì ní àwọn oògùn yìí, èyí kò sì yọ àwọn tó ti gba ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá sílẹ̀, wọ́n ṣì ń fi yangàn láwùjọ. Àpẹẹrẹ ni:

*Bó ṣelé, bó ṣoko*
*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ ọba akiti-káàka*
*Ọ̀bọ́nyin-bọnyìn oògùn...*
*Ọmọ asẹ́ tíí mumi kíkan-kíkan lójú ogun...*

Nítorí wí pé wọn kì í kọjá àyè wọn, wọn kì í sì í déédé jà, àti nítorí pe wọ́n jẹ́ ẹ̀yà kan tó lágbára púpọ̀, wọ́n kì í sábàá pàdánù ogun. Wọ́n máa ń fara balẹ̀, wọn kì í sì í ja ìjà ẹ̀bi. Fún ìdí èyí, wọn kì í jẹ̀bi tí ọ̀rọ̀ bá ṣebí ọ̀rọ̀ láàárín àwọn àti alámùúlégbè wọn tàbí ìlú yòówù kó jẹ́. Èyí ni a rí nínú oríkì wọn tó sọ pé:

*Ọmọ a-báni-jà-má-jẹ̀bi-ẹni*
*Dede ìgbà rèẹjọ́ Ẹ̀gbà ń jàre*

Orí-ọ̀rọ̀-afọ̀ mìíràn tí a rí nínú àwọn oríkì wọ̀nyí ni ìwà ìkónimọ́ra. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé akíkanjú ni àwọn akópa gbòógì inú àwọn ewì alohùn yìí lásìkò ogun, síbẹ̀, ẹ̀yà ènìyàn tó kóni mọ́ra ni wọ́n. Àwọn akópa yìí nífẹ̀ẹ́ àwọn ènìyàn gan an, wọ́n sì máa ń ṣètọ́jú àlejò àti àwọn alámùúlégbè wọn dáàdáa. "Ò-ṣílẹ̀kùn-palẹ̀kùn-dé" túmọ̀ sí pé ìgbàkugbà ni wọ́n ń fi àyè gba àlejò, wọ́n sì máa pèsè nǹkan ti àlejò tí wọ́n gbà sílé máa mú sí ẹnu (ẹrun). Ó ní:

*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ ò-ṣílẹ̀kùn-palẹ̀kùn-dé*
*Ọmọ a-jí-fọwọ́-àlejò-bẹrun...*
*Ọmọ onílé káyà-káyó...*

Kókó mìíràn ni pé wọ́n jẹ́ ìran ọlọ́rọ̀, ọ̀pọ̀ ìgbà sì ni èyí jẹ yọ ni oríṣiríṣi ọnà nínú oríkì wọn tí à ń gbé yẹ̀wò yìí. Nígbà tí àwọn apohùn yìí bá ń ṣàpèjúwe bí Ẹ̀gbá àti àwọn ìlú abẹ́ rẹ̀ ti lówó tó, kì í dà bí ẹni pé àwọn ẹ̀yà yìí mọ̀yà rárá, níbi ni a ti lè bá àwọn ìpèdè tó ń bu ọlá fúnni pàdé, tí ó sì buyì kún ènìyàn. Àwọn àyẹ́sí lóríṣiríṣi, láti bu ọlá fún ẹni tí ó yẹ fún ni ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí:

*Ọmọ a-rílé-jogún...*
*Ọmọ ṣẹkẹwúrú olówó ẹyọ àná tòjò-tẹ̀ẹrùn...*
*Àbàtà-bútú ọlọ́rọ̀ lọmọ Ẹ̀gbá*
*Ọmọ erínjogúnọlá*
*Ọmọ aṣẹ́fọ́n idẹ*
*Ọmọ A-pàtíbàbà-ìlẹ̀kẹ̀...*

Nínú oríkì Òkè-ọnà, ó ní:

*Ọmọ ọlá pọ̀ tító*
*Ọmọ ọlá kò nẹ́kun*
*Ọmọ ọlá ò ṣebìkan*
*Ọmọ agara ọlá dáni...*

Nínú ìgbìyànjú láti ṣàlàyé bí ọlá àwọn ẹ̀yà yìí ti tó, àpẹẹrẹ mìíràn ni pé ìlà kan nínú oríkì Òkè-ọnà tún ṣàkàwé bí ilé wọn ti ń fi bí wọ́n ti lówó tó hàn, àyọlò náà ní ẹni tó bá wọ àgbàlá wọn kì í fẹ́ lọ mọ́, níbi tí wọ́n ti sọ pé ọmọ alágbàlá tí a máa wọ̀ tí a ò ní fẹ́ lọ mọ́, ó ní 'ọmọ aláràlá ká wọ̀ má lọ'.

Orò jẹ́ pàtàkì nínú ìṣèlú àwọn Ẹ̀gbá, tí obìnrin kò gbọdọ̀ sí nítòsí lásìkò tí ó bá ń jáde. Inú igbó tí wọ́n ń pè ní Igbórò (Igbó Orò) ni ojúbọ rẹ̀ wà, yàtọ̀ sí àwọn ọkùnrin, *Orò* kò bá ènìyàn rẹ́ rárá. A rí èyí nínú oríkì wọn níbi tí 'igi' àti 'ọ̀pẹ̀' ti dúró fún gbogbo àwọn ènìyàn tó kù bí i àjèjì àti obìnrin, tí

'gbágùúdá' sì dúró fún àwọn ọkùnrin, nítorí wọ́n ní "ẹni tó mojú ògún ní í pabì nírè". Àwọn Ẹ̀gbá jẹ́ ẹ̀yà kan lára àwọn tí ó ń ṣe Orò. Èyí hàn nínú oríkì wọn pé olórò ni àtìrandíran wọn, ó ní:

*Ẹkùn abìjà wàrà lọmọ Orò nílé Ìgbèin...*
*Ọmọ yúnmù-yúnmù lorò ó ké*
*Ọmọ Orò ń pagi*
*Orò ń pọ̀pẹ̀*
*Ọmọ Orò kì í pa gbágùúdá*
*Ọmọ Orò ń jà rànyìn-rànyìn...*

A rí i bí Gẹ̀lẹ̀dẹ̀ tí àwọn akópa inú oríkì Ìbara ń bọ ti máa ń ṣe lásìkò ọdún nígbà tó bá ń jó lójú agbo nínú oríkì wọn. Wọn á wé gèlè mọ́ gbogbo ara wọn láti orí dé ilẹ̀, wọn á wá lọ̀ irin tí wọ́n ṣe bí i woroworo ọmọdé mọ́ ẹsẹ̀, yóò sì máa dún tẹ̀lé wọn bí wọ́n bá ti ń jó. Ó ní:

*Ọmọ olórìṣà kan òrìṣà kàn*
*Ìyí kórin sẹ́sẹ̀*
*Tó ń jó gbarege gbarege lójú agbo...*

Lẹ́yìn Orò tí gbogbo Ẹ̀gbá ń ṣe lápapọ̀, wọ́n tún ní òrìṣà tí wọ́n ń bọ ní Òkè-Ọnà tí wọ́n ń pè ní Akóògùn. Ènìyàn tó bá jẹ àjẹ̀jì ni wọ́n fi ń bọ òrìṣà náà, ó ní:

*Ọmọ olóòṣà yì ń fúnni ládìyẹ sìn tọmọtọmọ lójú ogun*
*Òòṣà Ìkèrèkú kò ma gbẹja*
*Kò ma gbèbùn*
*Àjèjì yìí bá ń bẹ nÍkèrèkú*
*Kó yáa mẹ́sẹ̀ rèẹre...*

A rí i nínú oríkì wọn, bákan náà, pé òrìṣà Ọ̀ṣun ni àwọn Àgùrá ń bọ, ó ní:

*Ẹni máa jẹ Àgùrá á dé ìdí Ọ̀ṣun...*
*Ọ̀ṣun tí wọ́n ń bọ*
*Ọ̀kánkán ilé ló wà*

Oríkì Ẹ̀gbá mẹ́nu ba ẹgbẹ́ Ògbóni Ẹ̀gbá lọ́nà àrokò, gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ tó ṣe pàtàkì nínú ìṣàkóso Ẹ̀gbá. Gbẹ̀du jẹ́ ìlú tí wọ́n máa ń lò ní ilé Ògbóni, èyí ló fi dúró fún ẹgbẹ́ Ògbóni:

*Ọmọ gòdòmù godomu gòdòmù*
*Ìyí wọ́n ń lùlù àgẹ̀rẹ̀...*
*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ Onígbẹ̀du Àlùlà*
*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ Onígbẹ̀du Àlùlówó lọ́wọ́...*

Nínú oríkì Aké bákan náà, a rí àpẹẹrẹ ẹ̀gbẹ́ Ògbóni níbi tí ó ti ṣe àkàwé bí ìlù gbẹ̀du tí wọ́n máa ń lù nínú ilé ìpàdé wọn ti máa ń dún, ó ní:

*Ọmọ onígbẹ̀du àbábá ribiribi*
*Ọmọ onígbẹdu bàbàrà n dinkù*
*Bí gbẹ̀dú bá ya*
*Bí kò bá ró*
*Awọ Ẹkùn ló kàn un*
*Tòun taketempe etí Erin...*

Àwọn akópa inú àwọn ewì alohùn yìí kì í ṣe ọ̀lẹ, bí wọ́n sì ti jẹ́ akínkanjú lójú ogun ni wọ́n jára mọ́ṣẹ́ ọ̀nà àtijẹ wọn, nítorí Yorùbá bọ̀ wọ́n ní "ìdí iṣẹ́ ẹni la ti í mọni lọ́lẹ". A rí àwọn iṣẹ́ òòjọ́ àwọn akópa

yìí nínú oríkì wọn. Ní ti gbogbo Ẹ̀gbá lápapọ̀, iṣẹ́ àgbẹ̀ àti iṣẹ́ awakọ̀ ni wọ́n yàn láàyò. Wọ́n mọ iṣẹ́ àgbẹ̀ yìí débi pé wọn kì í ṣi àsìkò mú, bí wọ́n bá fẹ́ kí òjò rọ̀ lásìkò kan sí ohun ọ̀gbìn wọn tí èrè oko wọn yóò sì yọ dáadáa, wọ́n ti mọ àsìkò tí àwọn gbọ́dọ̀ fúrúgbìn. Ní ti iṣẹ́ awakọ̀, bákan náà, wọ́n mọ̀ nípa rẹ̀ dáadáa. Ó ní:

*Ọmọ a-wí-kéjìdé*
*Ọmọ a-fọ̀-kíré-oko-ṣẹ*
*Ọmọ a-rọ́kọ̀-wa-Sàlàkọ́*
*A-rílé-jogún*
*Ọmọ a-rọ́kọ̀-wa-Dàda...*

Àwọn Ẹ̀gbá mọ̀ nípa òwò-ṣíṣe gan an ni, wọ́n sì nígbàgbọ́ nínú òwe tó sọ pe "àtẹ́lẹwọ́ ẹni kì í tanni jẹ", wọ́n máa ń ṣe oríṣiríṣi iṣẹ́ láti rí owó, èyí sì fún wọn ní àǹfààní láti gbajúmọ̀ ní gbogbo ọ̀nà. Òun ni wọ́n fi ń pè wọ́n ní 'Ọmọ ọ̀nà ò tibìkan wọjà'.

Kókó gbòógì tó jẹ yọ nínú àwọn ewì yìí ni ogun, àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó náà sì tún wà níbẹ̀. Àwọn nǹkan wọ̀nyí àti àwọn mìíràn ni orí-ọ̀rọ̀-afọ̀ tó jẹ yọ nínú àwọn oríkì Ẹ̀gbá àti olú ìlú abẹ́ rẹ̀.

### 5.1. ***Ìṣọwọ́ṣafọ̀***

Gbogbo àwọn oríkì tí à gbé yẹ̀wò ló jẹ́ ológun ló fẹ́rẹ̀ pọ̀ jù nínú àwọn akópa wọn. Nínú irú sàkání ìtumọ̀ tí ogun ti jẹ́ ohun tí wọ́n ń ṣe lójoojúmọ́ báyìí, ó yẹ kí ó yéni pé kò lè sí àjọṣepọ̀ tó máa dán mọ́nrán láàárín àwọn akópa ní àkókò tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ń wáyé. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti mọ̀, tí a tún rí i kà nínú Ajíṣafẹ́ (2005), pé ogun jẹ́ nǹkan tí àwọn ìlú kọ̀ọ̀kan tó para pọ̀ di Ẹ̀gbá fi gbogbo ìbẹ̀rẹ̀ ọjọ́ ayé wọn jà, tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn akọni sì fi ẹ̀mí wọn lélẹ̀ kí ìlú Ẹ̀gbá má baà parun, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìwúrí àsìkò náà ni ó sodo sínú àwọn oríkì náà lọ́nà àrokò. Àpẹẹrẹ èyí ni a rí nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí láti inú oríkì Ẹ̀gbá fúnraarẹ̀, tí ó ń sọ nípa àwọn akópa náà àti bí wọ́n ti jẹ́ akínkanjú tó, tó sì jẹ́ pé nǹkan kò rọrùn láàárín wọn àti àwọn ọ̀tá wọn. Tí ó bá di kí a fi ìyà jẹ ẹni tó bá rú òfin kan tàbí òmíràn láàárín ìlú, àwọn akópa inú ewì Ẹ̀gbá kì í wojú ẹnikẹ́ni rárá, wọ́n kórìíra kí èniyàn máa ṣe àfojúdi, wọ́n sì fi 'ayọ́nràn' dúró fún aláfojúdi tàbí aláìgbọràn ní àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

*Ẹ̀gbá lọmọ Líṣàbí Agbòṅgbò Àkàlà*
*Afipàkọ́ ayọ́nràn gbolẹ̀ túkẹ́-túkẹ́...*
*Ẹ̀gbá lọmọ agbogun lọ́wọ́ ojo...*
*Àgbà ńlá òjò tíí lékú wọlé kẹ̀rikẹ̀ri lójú ogun*
*Ẹkùn abìjà wàrà lọmọ orò nílé Ìgbèin...*

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ogun kò fìgbà kan má kojú àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí a mọ̀ sí Ẹ̀gbá yìí, síbẹ̀, wọn kì í ṣe oníjàgídíjàgan ẹ̀yà, ọ̀pọ̀ ogun tó máa ń kojú wọn ni ó jẹ́ pé kì í ṣe ìfẹ́ inú wọn. Wọn kì í kọjá àyè wọn, ara wọn sì kọ ìwọ̀sí, ṣùgbọ́n èyí kò túmọ̀ sí pé wọ́n ń bẹ̀rù ìjà, ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ni pé ìlú tó bá tọ wọn ló máa ń rìjà wọn. Àwọn ìpèdè ẹ̀hónú ló máa ń sábàá wáyé nínú irú àwọn sàkání bẹ́ẹ̀, ogun ò lè bí ọ̀rọ̀ tútù. Eléyìí jẹ yọ nínú oríkì wọn báyìí:

*Ẹ̀gbá a-ṣàálọ̀-kó-tó-dìjà-wàrà-wàrà*
*Ìwọ̀sí ọ̀rọ̀ ni mo kọ̀*
*L'Ẹ̀gbá fi ń jagun nílẹ̀ yìí bí àrìrà*

Ohun tí èyí ń jẹ́ kó yé wa ni pé àwọn akópa inú oríkì yìí tí wọ́n jẹ́ Ẹ̀gbá mọyì ara wọn púpọ̀, wọ́n kórìíra ìwọ̀sí gan an ni, wọ́n sì máa ń tiraka láti má ṣe ohun tó bá máa kó ìwọ̀sí bá wọn, bí ẹnikẹ́ni bá wá tasẹ̀

àgẹ̀rẹ̀ sí wọn, wọn á kílọ̀ fún irú ẹni bẹ́ẹ̀, kì í ṣe pé ẹ̀rù ìjà ń bà wọ́n, bí kò ṣe pé wọ́n mọ irú ohun tí àwọn lè ṣe bí àwọ́n bá bínú tán. Ohun tó yẹ irú ẹni tó bá tasẹ̀ àgẹ̀rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọmọlúàbí ni kó gbọ́, ṣùgbọ́n bí ó bá fojú di wọ́n, tí ó sì jẹ́ kí wọ́n yíjú padà sí òun, dandan ni ki ojú rẹ̀ rí ohun tí ó wá, nítorí wọn kì í yí ìpinnu wọn padà, oríkì wọn ní:

*Ẹ̀gbá lọmọ a-ṣojo-ṣíwájú-akin*
*Yíyọ́ kẹ́lẹ́-kẹ́lẹ́ Ẹkùn tojo kọ́ ni wọ́n*
*Kìlọ̀kìlọ Ẹkùn wọn kò ma ṣòjòjò...*
*Ẹ̀gbá kò ń sọ̀rọ̀ tọ́n*
*Kó dẹ̀ tún padà sọ́nọ̀ọ̀fun wọn*
*Ìyẹn ọ̀rọ̀ èèwọ̀...*

Wọn kì í yí ọ̀rọ̀ padà kí wọ́n ní àwọn ò sọ bẹ́ẹ̀ mọ́, ìgbéraga kọ́, wọ́n kàn kóríira ìwọ̀sí, wọ́n sì mọyì ara wọ́n ni. Bí wọ́n bá sì ṣe ìlérí láti ran ènìyàn lọ́wọ́ tàbí ta ènìyàn lọ́rẹ, gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ṣe, wọn kì í yẹ ìlérí. Fún ìdí èyí, ẹni tó bá mú wọn pinnu láti kọjú ìjà sí òun, kó mọ̀ pé òún ti kọjá àyè òun, yóò sì rí ìbínú tó kọ̀wé ránṣẹ́ sí. Èyí ni a rí nínú oríkì wọn tó sọ pé:

*Ẹní bá figi tọ́ bàtá Ẹ̀gbá lójú*
*Olítọ̀ún á gbọ́ pọnlá-pọnlà lójú awọ...*

Lásìkò tí ogun bá ń ṣẹlẹ̀ ní ààrín ìlú méjì, àwọn méjèèjì ni nǹkan ò ní rọgbọ fún, èyí ló fa ìpèdè tí a rí nínú oríkì Òkè-ọnà tó ni:

*Ọmọ adìyẹ gorókù ó kòtèǹgèlè*
*Ara kò rokù*
*Ara kò radìyẹ...*

Sàkání ìtumọ̀ tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú oríkì Ẹ̀gbá yìí ti ń wáyé ni agbègbè ibi tí kò ti sí ìfẹ́ àtọkànwá sí ẹnìkejì tàbí ìlú kejì, kò yẹ kí á rí àjọṣepọ̀ tó dán mọ́nrán kankan láààrín àwọn akópa náà, síbẹ̀ àwọn akópa yìí máa ń fìfẹ́ hàn sí àwọn ènìyàn, nítorí pé ìránṣẹ́ kan kò lè dí èkejì lọ́wọ́. Bí a bá tẹ̀lé gbogbo nǹkan tí a ti rí nípa àwọn akópa inú oríkì Ẹ̀gbá níwájú, a ó rò pé wọn kò ní ẹran ìfẹ́ kankan lára ni, ṣùgbọ́n kò rí bẹ́ẹ̀, ẹ̀yà ènìyàn tó kó ènìyàn mọ́ra dáadáa ni wọ́n, àtonílé àti àlejò. Ọ̀rọ̀ wọn ni à bá máa pè ní ohun tó kọ iwájú sí ẹnìkan, ẹ̀yìn ló kọ sí ẹlòmíràn, èyí ni a rí nínú ìpèdè ìsàlẹ̀ yìí:

*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ ò-ṣílẹ̀kùn-palẹ̀kùn-dé*
*Ọmọ a-jí-fọwọ́-àlejò-bẹrun...*
*Ọmọ onílé káyà-káyó...*

Ìrẹ́pọ̀ tó dán mọ́nrán ló ti wà láààrín àwọn akópa gbogbo àwọn oríkì yìí láti ìbẹ̀rẹ̀, èyí ló sì fún wọn ní àǹfààní láti máa ṣẹ́gun gbogbo àwọn ọ̀tá tó ń dojú kọ wọ́n, yálà bí ìlú kọ̀ọ̀kan ni tàbí lápapọ̀. Èyí ni wọ́n ń mú wá sí ìrántí pé kí ògiri wọn ó má lanu kí aláǹgbá ó má baà ráyè wọbẹ̀ nínú oríkì Ẹ̀gbá, ó ní:

*Ẹ̀gbá Aláké*
*Ẹ̀gbá Òkè-Ọnà*
*Ẹ̀gbá Àgùrá àti Ẹ̀gbá Òwu*
*Ìmùlẹ̀ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin Ẹ̀gbá*
*Ìfọwọ́ sowọ́pọ̀ ló sẸ̀gbá dọ̀kan*
*Ìmùlẹ̀ wọn ò gbọdọ̀ dawo ìmùlẹ̀...*

Nínú oríkì Ìbarà, a rí i pé ìbáṣepọ̀ tó dán mọ́nrán ló wà láàárín àwọn akópa inú ewì yìí àti àwọn Ẹ̀gbá tí wọ́n fàyè gbà lẹ́bàá ọ̀dọ̀ wọn, tí wọ́n sì ràn wọ́n lọ́wọ́ ní oríṣiríṣi ọ̀nà kí ìgbé-ayé wọn lè rọ̀ wọ́n lọ́rùn dáadáa níbẹ̀. Ó ní:

*Ìbarà*
*A-jí-bóró-dé*
*Aláyà gbẸ̀gbá dó*
*A-borí-kólú-igbó-jọ...*

Bí àwọn tí a pè ní Ìbarà yìí ti kó ènìyàn mọ́ra tó, tó bá di ọ̀rọ̀ ìjà, kì í sí ìbáṣepọ̀ gidi láàárín àwọn àti ẹni tí ọ̀rọ̀ bá ṣe bí ọ̀rọ̀ láàárín wọn rárá, kì-í-gbọ́-kì-í-gbà ni wọ́n. Ní àwọn àsìkò náà, àyè gbà wọ́n dáadáa fún ogun lóríṣiríṣi tí wọ́n bá fẹ́ jà, nítorí àwọn nìkan ni wọ́n wà ní agbègbè ibi tí wọ́n wà nígbà náà fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún. Wọ́n ní igbo lóríṣiríṣi tí wọ́n lè fi bora gẹ́gẹ́ bí ète láti ṣẹ́gun ọtá, èyí ni a rí nínú oríkì wọn tó ní:

*Ọmọ a-rigbó-jagun*
*Ọmọ onígẹ̀lẹ̀dẹ́ ilé Ìbarà*
*A-súré-jagun...*

Àwọn ìṣọwọ́ṣafọ̀ yìí àti àwọn mìíràn ni a rí nínú oríkì ìlú Ẹ̀gbá lápapọ̀ àti àwọn olú ìlú tó wà lábẹ́ rẹ̀.

5.2. ***Ọ̀nà ìgbàṣafọ̀***

Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé àwọn oríkì wọ̀nyí jẹ àtẹnudẹ́nu láti àìmọye ìran sẹ́yìn títí wá di àkókò tí a wà yìí, àwọn ìṣàmúlò èdè tí a ó máa bá pàdé nínú rẹ̀ kò lè ṣàìkún fún àwọn èdè àtijọ́ tí ó ti di àkànlò èdè báyìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ sì ni ẹwà-èdè àti ọnà-èdè tí ó kún inú àwọn oríkì náà. Àpẹẹrẹ ni:

*Ẹ̀gbá lọmọ agbogun lọ́wọ́ ojo...*

Ìlà yìí ń jẹ́ kó yéni pé ọmọ Ẹ̀gbá máa ń sábàá borí lójú ogun nígbà tí ogun náà kò bá yé ọ̀tá wọn mọ́, kì í ṣe pé ogun jẹ́ bí owó tàbí nǹkan àrídìmú tí a lè gbà lọ́wọ́ ènìyàn, èyí dàbí ìpàkíyèsí àwọn ọ̀tá sí. Àwọn ènìyàn rí àwọn akópa inú oríkì Òwù bí ẹ̀yà tí ó ṣoro láti mọ̀, wọ́n jẹ́ oríṣi ẹ̀yà ènìyàn tó wúwo púpọ̀ nípa iṣe wọ́n, nítorí ènìyàn kò lè tètè mọ bí nǹkan ti rí lára wọn gan an. Èyí ni àfiwé tààrà àti àwítúnwí awẹ́ gbólóhùn ínú oríkì wọn ń ṣàpèjúwe nípa bí a ti ń pe Òwu:

*Òwu à wúnu pè bí ẹ́n powó...*

Àwítúnwí awẹ́ gbólóhùn àti ìbádógba gbólóhùn tó jẹ yọ tẹ̀lé ìlà òkè yìí tún ń fi kún àpèjúwe náà sí i ni, ó ní:

*<u>Enu là á wú</u> powó*
*<u>Enu là á wú</u> pòwò*
*<u>Enu là á wu</u> pòdèrekókò nílé Òwu*

A rí àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ àti àfiwé tààrà nínú oríkì Àgùrá tó ń ṣàpèjúwe ajá tí babańlá wọn ní, tó jẹ́ pé ojú ogun ni wọ́n ti máa ń lò ó. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé gbogbo nǹkan ni ajá inú oríkì yìí fi jọ àwọn ẹranko tó máa ń ṣeni ní ìjàm̀bá, síbẹ̀, kì í ṣe ajá búburú. Bí wọ́n bá dé ojú ogun ni ó máa ń wúlò, ó ní:

*Ọmọ alájá dúdú ilé Ìdó*
*Tó fi <u>ara</u> dídán jọ <u>oká</u>*
*Ó fi <u>àwọ̀</u> lọ̀lọ̀ jọ <u>erè</u>*
*Ó ń gbó wẹwẹwẹ kò lè buni jẹ́...*
*Ọmọ alájá bẹ́kùnbẹ́kùn ni baba wọn lójú ogun...*

Òmíràn ni ìfọ̀rọ̀dárà nínú gbólóhùn méjì tó ń sọ nípa iṣẹ́ ọdẹ tí àwọn Òkè-Ọnà mọ̀ ọ́n ṣe dójú àmì. Àmì ohùn orí sílébù tó gbẹ̀yìn nínú 'a-palájá' yí padà nígbà tó jẹ yọ nínú ìlà kejì láti jẹ́ kí á mọ̀ pé kò sí nǹkan tí àwọn ọdẹ yìí kò lè ṣe tí wọ́n bá dé ojú iṣẹ́ tán. Ó ní:

*Ọmọ Kẹ́shinró*
*Ọmọ ọdẹ a-palájá-a-pajá*
*Ọmọ ọdẹ a-palájà-a-pa-Sàlàkọ́...*

Nínú oríkì Aké, a rí ibi tí wọ́n ti mẹ́nu ba ẹja Òjíjí, tí wọ́n máa ń fi pa tanwíjí nínú àmù láyé àtijọ́ gẹ́gẹ́ bí orílẹ̀ wọn, tí wọ́n sì mú un ní pàtàkì. Ẹja yìí ni wọ́n mú gẹ́gẹ́ bí ohun tí wọ́n ń bọ, bóyá nítorí agbára tó ní láti gbé ènìyàn tó bá fọwọ́ kàn án bí ẹni tí iná ẹ̀lẹ́tíríìkì gbé sọnù ni, èyí mú kí ó jọ wọ́n lójú pé ẹja lásán kọ́ ni ẹja náà. Wọ́n nígbàgbọ́ pé ẹja yìí lè gbara rẹ̀ sílẹ̀ lọ́wọ́ ìjàǹbá, èyí ló fa ìpèdè pé kí wọ́n kìlọ̀ fájèjì láti má pẹja ní Aké, nítorí ẹja fúnraarẹ̀ á ṣe ìdájọ́ fún ẹnikẹ́ni tí kò mọ̀ ọ́n tó fẹ́ pa á. Ìlà tó gbẹ̀yìn nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí ṣàmúlò ẹ̀ka-èdè Ẹgbá láti sọ pé kí wọ́n má pa ẹja Ìgángán ní inú odò ní Aké, ó ní:

*Ọmọ ẹja mẹ́gú ṣoró...*
*Ọmọ ẹja tó ń gbénú ibú ṣoró...*
*Ka má kìlọ̀ fájèjì*
*Ka má kìlọ̀ fájèjì*
*Pé kọ́n má pẹja àrọ̀ lÁké*
*Bọ́n ọn bá lè pẹja*
*Ẹ jẹ́ kọ́n-ọn-ọ́n pẹja*
*Ìgángán inódò rèe kọ́n ọn má pa*

Nínú oríkì Aké, a rí ìpèdè ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ kan tó sọ nípa ìyá kan nígbà ayé rẹ̀ tó máa ń ṣe ìṣekúṣe. Àmúlò ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ yìí ń sọ fún wa pé ìyá náà kì í ṣe alágbèrè, ìrìn rẹ̀ kàn jọ bẹ́ẹ̀ ni, ṣùgbọ́n àgbèrè yẹn gan an ni nǹkan tó ń gbìyànjú láti sọ fún ẹni tí ó bá ń gbọ́ ọ pé ìyá náà ń ṣe. Bí a bá ki Aláké Ọba Àdédọ̀tun Àrẹ̀mú Gbádébọ̀ (Òkúkẹ́nù IV) láìmẹ́nu ba ìpèdè yìí, a ò tì í kì í délé, ó ní:

*Ọmọ lékèélékèé ilé ìyá rẹ̀*
*A-bìnrìn-àgbèrè-lẹsẹ̀*
*A ṣe bó ń dọkọ ni*
*Ìyá rẹ kò dọkọ rí*
*Ìṣe rẹ̀ẹ wà...*

Àwọn ọ̀rọ̀ ìkàsè lórísirísi ló jẹ yọ nínú àwọn oríkì yìí, èyí ló sì máa jẹ́ kí á mọ rírì ìṣelọ́jọ̀ tí àwọn ohùn ẹnu náà ń ṣe, nítorí láti ayé àwọn babańlá wa ni wọ́n ti ń ṣàmúlò àwọn oríkì náà láti fi àwọn iṣẹ̀lẹ̀ pamọ́ fún àwọn ìran tí ń bọ̀ léyìn, kí wón lè mọ ipa ribiribi tí àwọn tó ṣẹ̀ wón ti kó nígbà ayé wọn nítorí kò sí ìmọ̀ mọ̀-ọn-kọ-mọ̀-ọ́n-kà láwọn àsìkò náà.

Àfiwé gbòógì tí a rí nínú oríkì Ẹgbá ni ẹlẹ́lọ̀ọ́, níbi tí wọ́n ti fi 'Ẹkùn' rọ́pò àwọn ọmọ Ẹgbá nítorí akínkanjú ni wọ́n lójú ogun. Bí a ti mọ̀ pé ẹranko ìbẹ̀rù ni Ẹkùn jẹ́, báyìí náà ni àwọn Ẹgbá ṣe máa ń rí bí wọ́n bá dójú ogun, iná ni wọ́n tí kò mẹni tó dá òun. Eléyìí jẹ yọ ní ọ̀pọ̀ ìgbà nínú ewì náà:

*Ekùn abìjà wàrà lọmọ orò nílé Ìgbèin...*
*Ọmọ Ekùn gẹ̀gẹ*
*Ọmọ olú Ekùn lórìyẹ̀*
*Ọmọ Ekùn rówó ìjà gọ̀dọ̀gọ̀dọ̀...*
*Yíyọ́ kẹ́lẹ́-kẹ́lẹ́ Ekùn tojo kọ́ ni wọ́n*
*Kìlọ̀kìlọ Ekùn wọn kò ma ṣòjòjò...*

A rí ìfirósínròòjẹ nínú oríkì Ẹ̀gbá tó ń ṣàpèjúwe ìlù tí wọ́n máa ń lò ní ilé Ògbóni, ó ní:

*Ọmọ gòdòmù godomu gòdòmù*
*Ìyí wọ́n ń lùlù àgẹ̀rẹ̀...*

Ìfiromọ̀risí tó ń jẹ kí á mọ bí *Gẹ̀lẹ̀dẹ́* ti máa ń jó lojú agbo náà jẹ yọ nínú oríki Ìbarà:

*Tó ń jó gbarege gbarege lójú agbo...*

Ìfirómọ̀risí mìíràn ni a rí nínú oríkì Ẹ̀gbá tó ń sọ fún wa bí agbára àwọn Ẹ̀gbá ti pọ̀ tó. Eléyìí ń mú ìwú
bá àwọn ọmọ Ẹ̀gbá tòótọ́, 'ọ̀bọ́nyín-bọnyìn' nínú oríkì yìí sì ń jẹ́ kó yé wa pé ẹni tó bá dojú ìjà kọ wọ́
yóò mọ pé mádàárikàn ni wọ́n jẹ́, ó sì ń jẹ́ kó yé wa pé wọ́n máa ń fi yangàn níbikíbi ni, ó ní:

*Bó ṣelé, bó ṣoko*
*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ ọba akiti-káàka*
*Ọ̀bọ̀nyìn-bọnyìn oògùn...*

Oríṣi àwọn ìlò-èdè tí a ṣàmúlò nínú àwọn oríkì yìí ló jẹ́ àwọn iṣẹ́ tí a fi rán wọn, wọ́n sì mú ẹwà tó y
bá ìgbélárugẹ àwọn ewì alohùn ẹ̀yà Yorùbá tí à ń pè ni Ẹ̀gbá àti àwọn olú ìlú tó wà ní abẹ́ rẹ̀.

5.3. ***Ọ̀gangan-ipò-àṣà***

Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ọ̀gangan ipò àṣà, èyí ni mímúwá sí ìrántí ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ní àkókò kan nínú ìtà
Nígbà mìíràn, ó lè jẹ yọ lọ́nà tààrà, nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ó lè wáyé lọ́nà bí àfiwé tàbí bí ẹni pé ènìyàn
pàṣamọ̀. Àwọn èyí tí ó máa ń jẹ yọ nínú àwọn oríkì orílẹ̀, tàbí àwọn ewì alohùn bayìí, máa ń sábà j
èyí tí ó lọ tààrà nítorí kì í ṣe ti ẹnìkan pàtó, bí i ti àwọn ewì àpilẹ̀kọ tí ó jẹ́ pé ẹni tí ìtàn náà bá ṣẹlẹ̀ sí l
pe ẹni tí ó bá ṣàmúlò rẹ̀ nínú iṣẹ́ rẹ̀ lẹ́jọ̀. Nínú ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá ni a ti rí i kà pé ọmọbìnrin Odùduw
bẹ̀bẹ̀ fún adé ni, nítorí ọkùnrin ló ń jọba nílẹ̀ Yorùbá, ọmọ tí ọmọbìnrin ọ̀hún bí ló jọba ìlú Òwu lá
ìbẹ̀rẹ̀.

Ìtàn mìíràn tún sọ fún wa pé nígbà tí ọba tí ó kọ́kọ́ jẹ, tí ó jẹ́ ọmọ tí ọmọbìnrin Odùduwà bí, w
ní kékeré, ó ń sunkún pé òun fẹ́ gba adé orí bàbá àgbà rẹ̀ nígbà tí ọba náà gbé e sórí ẹsẹ̀ tó ń bá a ṣer
tí ó sì jẹ́ pé ẹ̀yìn tí bàbá náà gbé adé lé e lórí ló yé ẹkún ún sun. Èyí ló fà á tí a fi máa ń ki àwọn Ẹ̀gb
Òwu ní:

*Ọmọ asunkún-gbadé...*
*Ọmọ a-ké-lamba ṣẹ̀kẹ́ yọ̀yọ̀yọ̀*
*Ọmọ atẹ́nígboyè*
*Ọmọ àbẹ̀bẹ̀gboyè*
*Ọmọ arọ́wọ́ mẹ́wẹ̀ẹ̀wá gboyè nílé Òwu...*

A rí àyọlo tó ń sọ fún wa nípa bí àwọn ará Kéesì, tí ọba wọn ń jẹ́ Lákésìn, ṣe ń hu ìwà ì-mọ̀-tara-ẹn
nìkan. Ṣáájú ọdún 1830, nígbà tí wọ́n wà ní Igbó Ẹ̀gbá, kó tó di pé wọ́n dífá yan Aké gẹ́gẹ́ bí orí Ẹ̀gb
abúlé Kéesì nìkan ni ó ń gbin àgbàdo fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún. Bí wọ́n bá fẹ́ ta àgbàdo yìí, wọn á bọ̀ ọ́ nín
omi gbígbóná, kí ó má baà hù nígba tí àwọn tó rà á bá gbìn ín sí oko tiwọn náà. Ọba Aláké àsìkò
Òjoko jẹ́ Lákésìn wá fi ọmọ rẹ̀ obìnrin, Adéṣíkù, fún Òjoko Ọba Kéesì ní àkóko tí wọ́n ń ṣe ọdú
àgbàdo kan ní Kéesì, kí ó lè lọ wá ìdí bí wọ́n ṣe ń gbin àgbàdo tó fi ń hù lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbìyànjú.

*Ọmọ Lákésìn*
*Ọmọ òru là á ṣèkà*
*Ènìyàn tó ṣerú ẹ̀ lọ̀sàn-án*
*Olúwaarẹ̀ ò ní lè faraare lọ...*

Nígbà tí Adéṣíkù rí i pé wọ́n máa ń bọ àgbàdo ni, ó wá dá ọgbọ́n fífún àwọn adìyẹ mẹ́ta ní àgbàdo tí wọn kò tí ì bọ̀ jẹ, ó sì fi àwọn adìyẹ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà ránṣẹ́ sí bàbá rẹ̀ pé kí ó gbin àwọn àgbàdo tó bá ti bá nínú ìjẹ̀kà àwọn adìyẹ náà. Alákẹ́ náà tẹ̀lé ọ̀rọ̀ ọmọ rẹ̀, lẹ́yìn oṣù mẹ́ta, àgbàdo bẹ̀rẹ̀ sí hù jáde níbi tí wọ́n gbin àwọn tí wọ́n bá nínú ìjẹ̀kà àwọn adìyẹ ọjọ́sí sí. Nígbà tí àwọn ará Kéesì gbọ́, wọ́n wádìí ọ̀rọ̀ náà, wọ́n sì rí i pé olorì tuntun nìkan ni títú àṣírí náà wúlò fún, wọ́n sì dá ẹjọ́ ikú fún un. Ọ̀rọ̀ yìí fa ọ̀pọ̀lọpọ̀ rògbòdìyàn, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀mí ló sì lọ sí i, ṣùgbọ́n wọ́n parí rẹ̀ nígbẹ̀yìn, àwọn ìlú tó kù náà sì bẹ̀rẹ̀ gbingbin àgbàdo. Oríkì wọn ní:

*Onílé Kéesì*
*Ọmọ a-rómi-gbé yangan...*

Ẹ̀gbá kì í fàyè gba ìwà kòtọ́, fún ìdí èyí, ìka tó bá ṣẹ̀ ni wọ́n máa ń gé. Nínú ìtàn Lísàbí (Ajíṣafẹ́ 1972, Ògúnwọ̀ólú 2007) ni a ti fìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí àwọn Ìlàrí Ọlọ́yọ̀ọ́ ń jayé alákátá láàárín àwọn Ẹ̀gbá, Lísàbí ru àwọn akínkanjú Ẹ̀gbá sókè láti fimú àwọn oníṣẹ́ ọba náà dánrin, wọ́n sì pa àṣà wọn rẹ́ láàárín wọn títí láé. Èyí lá rí nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí nípa ohun tí wọ́n máa ń fi ojú aláìgbọràn rí:

*Ẹ̀gbá lọmọ Lísàbí Agbòǹgbò Àkàlà*
*Ẹ̀gbá lọmọ afipàkọ́ ayọ́nràn gbolẹ̀ túkẹ́-túkẹ́...*

*Ọmọ olóòṣà yì ń fúnni ládìyẹ sìn tọmọtọmọ lójú ogun*
*Òòṣà Ìkèrèkú kò ma jẹja*
*Kò ma jàgbò*
*Àjèjì yìí bá ń bẹ nÍkèrèkú*
*Kó yáa mẹ́sẹ̀ rẹ̀ẹre...*

Àyọlò òkè yìí ń sọ nípa òrìṣà kan tí wọ́n máa ń sìn ní Òkè-ọnà tí wọ́n ń pè ní *Akóògùn*, òrìṣà yìí kì í gba ẹran lásìkò tí wọ́n bá ń bọ ọ́, ènìyàn tó bá jẹ́ àtọ̀húnrìnwá ni wọ́n máa ń fi bọ ọ́.

A rí ìwà ìkónimọ́ra tí àwọn ọmọ Ẹ̀gbá fi hàn sí Henry Townsend nígbà tó kọ́kọ́ wá sí ìlú Abẹ́òkúta ní ọjọ́ kẹ́rin sí ọjọ́ kẹwàá, oṣù kìíní ọdún 1843 (04-10/01/1843), nínú oríkì wọn. Ṣódẹkẹ́, Balógun ìlú Ìpóró tí ó gbà wọ́n sí ilé rẹ̀ ṣe wọ́n dáadáa, ó sì yà wọ́n lẹ́nu púpọ̀. Ẹgbàá owó-ẹyọ àti odindi àgùntàn ni ohun tó kọ́kọ́ fi ṣe é lálejò, èyí sì mú kí ó lè padà wá lẹ́ẹ̀kejì pẹ̀lú Samuel Àjàyí Crowther ní ọjọ́ kẹ́ta ọṣù kéjọ ọdún 1846 fún iṣẹ́ ìránṣẹ́ tí wọ́n fẹ́ wá ṣe gan an. Ó ní:

*Gbogbo Ẹ̀gbá lọmọ ò-ṣílẹ̀kùn-palẹ̀kùn-dé*
*Ọmọ ajífọwọ́ àlejò bẹrun...*
*Ọmọ onílé káyà-káyó...*

Ní abala yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn akópa tí ó wà nínú àwọn oríkì ìlú Ẹ̀gbá àti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀. Àwọn sàkání ìtumọ̀ tí àwọn oríkì náà ti jẹ yọ sì jẹ́ ojú ogun, nígbà tí gbàgede jẹ́ àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ, pàpápàá jù lọ ìlú Ẹ̀gbá, nígbà tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àjọṣepọ̀ láàárín àwọn akópa náà kò rọgbọ rárá, nítorí iṣẹ́ à-fojoojúmọ́-ṣe ni ogun jẹ́ ní àwọn àsìkò tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwọn oríkì náà ń wáyé. Bákan náà ni a tún ṣe àfàyọ àwọn ìmọ̀ inú àwùjọ tí àwọn akópa náà mú wọ inú ìṣe. Iṣẹ́ yìí ṣàfihàn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun tí àwọn ewì alohùn yìí ṣàkóónú ní ọ̀nà àrokò, tí kò hàn sí gbogbo ènìyàn, tó sì ṣe é ṣe pẹ̀lú ìṣàmúlò tíórì ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ.

## 6. Àgbálọgbábọ̀

Pàtàkì ohun tí a gbéyèwò nínú iṣẹ́ yìí ni oríkì Ẹ̀gbá àti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀ tí a sì fi tíórì ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ inú oríkì náà. Ohun tí a gbìyànjú láti wò nínú iṣẹ́ yìí ni àjọṣep tó wà láàárin iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀, pàápàá oríkì, àti àwùjọ Yorùbá. A sì rí i dájú pé àwọn ìṣẹ̀l àwùjọ láti ọjọ́ pípẹ́ wá ni a máa ń sọ lọ́jọ̀ sínú oríkì, pàápàá jù lọ orílẹ̀ Yorùbá. Ó ṣe é ṣe kí á tún rí ir iṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ nínú ìgbésí ayé àwọn ọmọ irúfẹ́ ìran bẹ́ẹ̀. Àfojúfò àwọn lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, pàápàá jù l àwọn oríkì orílẹ̀ àti bí ọjọ́ iwájú wọn yóò ṣe rí ló ṣokùnfà fífúnka mọ́ oríkì Ẹ̀gbá àti àwọn olú ìlú abẹ́ r fún iṣẹ́ yìí.

Tíọ̀rì ìmọ̀-ìlò-àmì-ajẹmáwùjọ tí a lò fún àgbéyẹ̀wò àwọn oríkì yìí jẹ́ kí á ní òye tó jinlẹ̀ níp ìtàn ìlú Ẹ̀gbá, àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó bí àwọn oríkì náà. Iṣẹ́ yìí tan ìmọ́lẹ̀ sí ìgbéayé àwọn Ẹ̀gbá, láti ìbẹ̀r pẹ̀pẹ̀ pé nǹkan kò rọgbọ̀ fún wọn rárá, ìgbéayé ojú ni alákàn fi ń ṣọ́rí ni wọ́n ń gbé nígbà náà, àìmọy ìgbà ni àwọn ìpèdè tó ṣàfihàn èyí sì jẹ yọ nínú àwọn oríkì wọn.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni kókó tó jẹ yọ nínú oríkì Ẹ̀gbá àti ti àwọn olú ìlú abẹ́ rẹ̀, lára rẹ̀ ni iṣẹ́ ogun àfojoojúmọ́ ṣe, iṣẹ́ àjogúnbá wọn lóríṣiríṣi bí ọdẹ, àgbẹ̀, awakọ̀ ojú-omi, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A tún rí ìwa ìkónimọ́ra wọn àti àwọn kókó mìíràn. Bákan náà ni a rí ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ́ àwọn ẹ̀yà Yorùbá yìí nínu oríkì wọn bí Orò, Ọ̀ṣun, Akóògùn, Gẹ̀lẹ̀dẹ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, àti díẹ̀ lára àwọn ọ̀nà tí wọ́n ń gbà ṣe àwọn ẹ̀sìn yìí. Àgbékalẹ̀ àwọn oríkì yìí wuni púpọ̀ pẹ̀lu ìlò-èdè tó ń gbé ẹwà iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ yọ lọ́nà tó wuyì. Iṣẹ́ yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé oríkì orílẹ̀ jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí ènìyàn lè fi wádìí ìtàn tòótọ́. Ọ̀pọ̀ oríkì ló sì fara sin nílẹ̀ Yorùbá tí kò tí ì sí ìwádìí lórí wọn.

### Àwọn Ìwé Ìtọ̀kasí


Abímbọ́lá, W. (1977). *Awọn ojú odù mẹ́rìndínlógún*. Ìbàdàn: University Press Limited.

Adéọ̀ṣun, H. O. (2012). Towards a socio-semiotic model for the analysis of Yorùbá Written Poetry. In *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria, Vol.7 (1), pp. 104-134*. Ìbàdàn: Hakolad Prints.

Adéyẹmí, R. O. (2014). Fífi tíọ̀rì sọṣìọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ṣe àtúpalẹ̀ oríkì Aláàfin Ọba Làmídì Adéyẹmí Kẹta. In *Abdussalam, A. S. (Ed.) Bringing Our Cultures Home: Festchrift forBade Ajayi At 70, pp. 151-161*. Ìlọrin: Chrimadel Publishing House.

Àjàyí, B. (2014). *Ọ̀fọ̀: The Yorùbá incantation (A textlinguistic exploration analysis)*. Ìlọrin: Chrimadel Publishing House.

Ajíṣafẹ́, A. K. (1972). *Ìwé ìtàn Abẹ́òkúta*. Abẹ́òkúta: The Hadcore Society.

Ayéláàgbé, B. (2013). Àrùngbè: orin orò Ẹ̀gbá. M.A. Dissertation Submitted to the Department of African Languages and Literature, Obafemi Awólọ́wọ̀ University,Ilé-ifẹ̀.

Babalọlá, A. (1973). *Orin Ọdẹ fún Àṣẹyẹ*. Lagos: Macmillan Nigeria Publishers Ltd.

Babalọlá, A. (1975). *Àwọn Oríkì Bọ̀rọ̀kìnní*. Ìbàdàn: Baptist Press Limited.

Bisiriyu, M. (2014). Oríkì (Praise-singing) Practice. In *Abdussalam, A. S. (Ed.) Yorùbá Culture. Bringing Our Cultures Home: Festchrift for Bade Ajayi At 70. pp.162-173*. Ìlọrin: Chrimadel Publishing house.

Halliday, M. A. K. (1978). *Language as social semiotic: The social interpretation of meaning.* London: Edward Arnold.

Harris, H. S. (2006). *Socio-semiotic approach in transition: Two models revisitedretrieved from* http://usd.ac.id/06/publdosen/phenoma/jeb06/harris.pdf

Hodge, R. & Kress, G. (1988). *Social semiotics.* Cambridge, U. K.: Polity Press.

Líjàdu, M. (1974). *Àwọn àròfọ̀ Ṣóbọ̀ Aróbíodu 1902 & 1906.* Lagos: Macmillan Nigerian Publishers Ltd

Ògúnfọlákàn, A. (2002). *West-Afrian journal of archaeology* 32(2), pg. 97-122 culled from www.africabib.org/index.htm

Ògùnṣínà, B. (1987). The sociology of the Yorùbá novel: A study of Isaac Thomas, D.O.Fágúnwà and Ọládẹ̀jọ Òkédìjí. Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ìbàdàn.

Ògúnwọ̀ólú, L.A.K. (2007) *Ètò, Àṣà àti Ìṣèlú ìlú Ẹ̀gbá.* Abẹ́òkúta: Unipoint Commercial Enterprises. Educom Ventures.

Ọlábímtán, A. (1971). Ọfọ̀ àti àyájọ̀: Two categories of Yorùbá traditional incantatory poetry. M.A. Dissertation, University of Lagos.

Ọlátúnjí, Ọ. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry.* Ibàdàn: University Press Limited.

Shotunde, F. I. (2010). *Ẹ̀gbá Ògbóni; The reformed Ògbóni fraternity (R.O.F.) and catholicism.* Abẹ́òkúta: Akanbi and Associates

Thibault, P. J. (1991). *Social semiotics as praxis: Text, social meaning making, and Nabakov's Ac* Minneapolis: University of Minnesota Press.

**Rẹ́kọ̀ọ̀dù àti fíìmù tí a lò**

Afọláyan, K. (2015). *Ibùsùn.* Epsalum Movie Productions Ltd.

Ayélàágbé, B. (2015). *Ẹ̀gbá d'ọ̀tun.* Abẹ́òkúta: Àjíkì-Olú Music & Films

Ayélàágbé, B. (2015). *T'Olúwàṣẹ.* Abẹòkúta: Summit Global Ent.

'Túbọ̀sún Ọládàpọ̀ (1830-1980). *Lórí òkè àti pẹ̀tẹ́lẹ̀.* The Líṣàbí Elite of Nigeria Abẹ́òkúta. Abẹ́òkúta: Olatubosun Records Company.